# Ìfarahàn Ìmọ̀ Abínibí nínú Ewì Àpilẹ̀kọ Yorùbá fún Ìmúdúró-Ṣọ̀kan Ìṣèlú Nàìjíríà

**Oyèwálé, Ayọ̀délé Solomon**
*Department of Linguistics, African & Asian Studies*
*University of Lagos, Lagos.*
*ayoako2002@yahoo.co.uk*

## Àṣamọ̀

*Bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé ìlànà ètò ìṣèlú ẹ̀yà kọ̀ọ̀kan tó para pọ̀ di orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ṣòtọ̀ọ̀tọ̀, síbẹ̀, àwọn ìjọra wà tí a lè tọ́ka sí. Ètò ìṣèlú Yorùbá àti ìlànà tí wọ́n fi ń ṣèlú pẹ̀lú ìmọ̀ abínibí wọn àti ìwúlò rẹ̀, ní ìbámu pẹ̀lú bí àwọn akéwì àpilẹ̀kọ Yorùbá ṣe gbé e kalẹ̀ láti fi wo ibi tí nǹkan dé dúró nínú ìṣèlú Nàìjíríà ni a gbé yẹ̀wò nínú iṣẹ́ ìwádìí yìí. Bí a bá fi ojú oríkì tí àwọn onímọ̀ fún àṣà wò ó, bákan náà ni gbogbo àṣà ẹ̀yà kọ̀ọ̀kan ní àgbáyé ṣe níye lórí sí. Ìdí nìyí tí a fi ṣe àmúlò àṣà ẹ̀yà Yorùbá fún iṣẹ́ ìwádìí yìí lórí ọ̀nà bí ìmọ̀ abínibí ṣe lè ràn Nàìjíríà lọ́wọ́ fún ìmúdúró-ṣọ̀kan. Àkíyèsí wà pé àyípadà ọ̀làjú ti bá àṣà ìṣèlú àwùjọ Yorùbá, síbẹ̀síbẹ̀, wọ́n ṣì mú ìlàná ètò ìṣèlú wọn lọ́kùn-ún-kúndùn. Àpilẹ̀kọ yìí dá lórí àgbéyẹ̀wò oríṣiríṣi ìmọ̀ abínibí ilẹ̀ Yorùbá nípa ìṣèlú, ìṣọ̀kan, ìdájọ́ àti ọ̀nà tí àwọn akéwì àpilẹ̀kọ Yorùbá gbà fọn rere rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí èròjà tí Nàíjíríà lè mú lò fún ìmúdúró àti ìdàgbàsókè ìṣèlú rẹ̀ nípasẹ̀ tíọ́rì ajẹmáṣà. Ìgúnlẹ̀ àpilẹ̀kọ yìí fi hàn kedere pé ṣíṣe àmúlò ìmọ̀ abínibí nínú ìṣèlú ìjọba tiwa-n-tiwa ní Nàìjíríà lè ṣe ìrànlọ́wọ́ láti wá ojútùú sí àwọn ìṣòro tó ń fi ìṣèlú orílẹ̀-èdè yìí lògbòlògbò lórí/nípa ìmúdúró, ìdàgbàsókè àti ìtẹ̀síwájú Nàìjíríà.*

**Kókó Ọ̀rọ̀:** Ìmọ̀ abínibí Yorùbá, Ètò ìṣèlú/ìdájọ́, Ìmúdúró-ṣọ̀kan, Nàìjíríà, Ewì àpilẹ̀kọ

## Ìfáárà

Láti àtètèkọ́ṣe àti ìṣẹ̀dá ènìyàn ni ìṣèlú ti bẹ̀rẹ̀. Àmọ́, ọ̀nà tí àwọn ènìyàn ń gbà ṣe é ní ìbámu pẹ̀lú ìṣẹ̀dálẹ̀ wọn ló yàtọ̀ láti agbègbè kan sí èkejì. Ọ̀rọ̀ nípa ìṣèlú ìlú kan, ẹ̀yà kan tàbí ti orílẹ̀-èdè lápapọ̀ jẹ́ ohun kan tí ó ṣe kókó fún tẹrú-tọmọ. Ìdí ni wí pé ẹnìkọ̀ọ̀kan ni ọ̀rọ̀ ìṣèlú ní ipa lórí rẹ̀ lọ́nà kan tàbí òmíràn. Yorùbá bọ̀ wọ́n ní, *Ìlú kì í wà kó má ní olórí, ọba kì í jẹ kó má ní olorì*. Bẹ́ẹ̀ sì ni, ìlú ò dédé dùn, onílùú ló tẹ iṣan mọ́ ọn. Payne & Nassar (2006:2) ṣe àpèjúwe ìṣèlú gẹ́gẹ́ bí "ọ̀nà tí àwùjọ ń gbà ṣe ètò ìgbésí ayé wọn lápapọ̀". Bí ìlú tàbí orílẹ̀-èdè kan bá wá dojúkọ ìṣòro ìṣèlú, èyí jẹ́ nǹkan tó pè fún àkíyèsí fún gbogbo ènìyàn; pàápàá láti ọ̀dọ̀ àwọn tó ní òye nípa àtúnṣe fún ìfẹsẹ̀rinlẹ̀ àti ìmúdúró-ṣọ̀kan ètò ìṣèlú àti ọrọ̀-ajé. Ohun tó jẹ wá lógún nínú iṣẹ́ àpilẹ̀kọ yìí ni ìpèníjà ajẹmọ́-ìṣèlú tó dà bí èyí tí kò ní ìrètí nítorí hílàhílo ìṣèlú Nàìjìríà jẹ́ *àlàfo ìdáyàfoni* lórí ìmúdúró-ṣọ̀kan orílẹ̀-èdè Nàìjíríà.

Bákan náà, a gbìyànjú láti wo ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ ìṣèlú orílẹ̀-èdè Nàìjíríà pẹ̀lú èròǹgbà láti wo ìtàn ibi tí ọ̀rọ̀ ti wọ́ wá. Ojú sùnnùkùn tí àwọn onímọ̀ àti akéwì àpilẹ̀kọ Yorùbá lọ́kan-ò-jọ̀kan fi wo bí nǹkan ṣe ń lọ nínú ètò ìṣèlú Nàìjíríà. Àbá wọ́n tún jẹ́ kókó kan pàtàkì tí a gbéyẹ̀wò. Ìdí abájọ ni pé ìfẹ́ àti ìgbàgbọ́ tí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọmọ Nàìjíríà ní sí ilẹ̀ baba wọn ti di kò-gbóná-kò-tutù. Ọ̀rọ̀ orí-ahọ́n, àsọjẹ àti àsọyínmú ni púpọ̀ ń fi ọ̀rọ̀ ṣe bí a bá pe "Nàìjíríà ní orílẹ̀-èdè kan". Àwọn àpólà-orúkọ à-fi-ṣàpọ́nlé-ara-ẹni bí *Giant of Africa*, *Good People*, *Great Nation* àti *One Nation*, kò fi bẹ́ẹ̀ ní ìtumọ̀ létí àwọn ọmọ Nàìjíríà àti ilẹ̀ òkèèrè

mọ́. Ìpolongo-ìwà-rere-ara-ẹni lásánlàsàn ni ọ̀pọ̀ ènìyàn ń kà á sí.

Àwíjàre àwọn akéwì àpilẹ̀kọ Yorùbá nípa bó ti ṣe pàtàkì tó kí ìjọba Nàìjíríà ṣe àmúlò ìmọ̀ abínnibí nínú ìlànà/ètò ìṣèjọba wọn bí àfikún sí ìlànà ìṣèlú ìjọba tiwa-n-tiwa jẹ́ ẹ̀rí tó dájú tí kò ṣe é takò. Orísun èròjà tí a lò ni àṣàyàn ewì àpilẹ̀kọ Yorùbá. Lápapọ̀, ewì àpilẹ̀kọ mẹ́sàn-án ni a ṣe ìtúpalẹ̀ rẹ̀. Àwọn akéwì àpilẹ̀kọ Yorùbá tí a lò ewì wọn ni: Ọládàpọ̀ (1973 - *Àjọ̀dún òmìnìra*); Ọ̀pádọ̀tun 1976 - *Àríyá ọdún kẹtàlá t'áa gbòmìnira*); Adéwọlé (1987 - *Àlàáfíà*); Adétúnjí (1989 - *Ìṣọ̀kan*); Ẹlẹ́buìbọn (1999 - *Àwọn Ọ̀jẹ̀lú*); Òkédòkun - (2003 *Nígbà Tàwa*); Adélékè (2010 - *Nàìjíríà Dòrí*); Ṣàngótóyè - (2010 - *Ètùtù Ìṣọ̀kan*); Àtàrí Àjànàkú (2011 - *Níbo Là ń rè?*). Òsùnwọ̀n tí a lò fún yíyan àwọn ewì àpilẹ̀kọ tí a lò dúró lórí pé ọ̀rọ̀ nípa ìmọ̀ abínibí àti ìṣèlú jẹyọ nínú ewì àpilẹ̀kọ àwọn akéwì náà. A ṣe ìtúpalẹ̀ àwíjàre àwọn akéwì wọ̀nyí lórí ọ̀nà tí wọ́n gbà fi ẹ̀rí múlẹ̀ pé ìmọ̀ abínibí wúlò nínú ìṣèlú nípa lílo tíọ̀rì ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀ wo nǹkan.

## Tíọ̀rì Ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀ wo Lítíréṣọ̀

Ọ̀nà méjì pàtàkí tí a gbà ṣe iṣẹ́ ìwádìí yìí ni pé a ṣe iṣẹ́ lámèyítọ́ lórí ọ̀nà tí àwọn akéwì àpilẹ̀kọ Yorùbá gbà gbé àṣàrò wọn kalẹ̀ nínú ewì wọn nípa lílo tíọ̀rì ìfi-ojú-àṣà-ìbílẹ̀ wo lítíréṣọ̀. A ṣe àfiwéra àwọn kókó-ọ̀rọ̀ ajẹmóṣèlú tó jẹyọ pẹ̀lú àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ abáyému láti ṣàgbéyẹ̀wò ojú-àmúwayé àti àkíyèsí àwọn akéwì àpilẹ̀kọ Yorùbá nípa ipò tí ìṣèlú Nàìjìríà wà. Àwọn tó ṣẹ̀dá tíọ̀rì ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀-wo-lítíréṣọ̀ ṣe ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé pé ojúlówó iṣẹ́ lítíréṣọ̀ láwùjọ ẹ̀dá ni láti dáàbò bo àṣà àwùjọ (Adéyẹmí, 2006).

A tún lè fi ojú ọ̀tun, nítorí ìdàgbàsókè, wo àṣà àwùjọ èyí tí ó ṣeé ṣe kí a rí àyípadà titun fàyọ nínú rẹ̀. Brannigan (1999) ní tirẹ̀ sọ pé ohun pàtàkì tí a ní láti mọ̀ nípa tíọ́rì yìí ni wí pé lítíréṣọ̀ àti ẹ̀kọ́ ìtàn kò ṣe é yà sọ́tọ̀. Ẹ̀ka ìmọ̀ méjèèjì yìí fi ara mọ́ ìdàgbàsókè ẹnìkọ̀ọ̀kan nínú ìbáṣepọ̀ bù-fún-mi-n-bù fún-ọ nínú àṣà agbègbè/àwùjọ kọ̀ọ̀kan. Yàtọ̀ sí èyí, àwọn ènìyàn àwùjọ lè jìjàgbara kúró lọ́wọ́ àwọn ohun tó dúró bí ìdíwọ́ tàbí ìfàsẹ́yìn láti mú àyípadà rere bá àwùjọ (Tyson, 1999). Lára àwọn ìbéèrè tó jẹyọ nípa àmúlò tíọ́rì ìfojú-àṣà-wo-iṣẹ́-ọnà lítíréṣọ̀ nìwọ̀nyí :

(i) Kí ni àwọn ohun ajẹnilógún tí iṣẹ́-ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀ fúnka mọ́?

(ii) Ǹjẹ́ ìyàtọ̀ wà láàrin ohun tó jẹ òǹkàwé lógún àti ohun tí ìwé lítíréṣọ̀ tó ń kà kà sí ohun àmúyẹ?

(iii) Irú ìhùwàsí àwòkóṣe ìmúṣe ìfipámúníṣe wo ni ìwé tí a kà ń tọ́ka sí?

Àwọn àbùdá tíọ́rì yìí wúlò fún ìtúpalẹ̀ kókó-ọ̀rọ̀ tó jẹ́ àfojúsùn wa nínú iṣẹ́ yìí gẹ́gẹ́ bó ṣe jẹyọ nínú àwọn àṣàyàn ewì àpilẹ̀kọ Yorùbá tí a lò. A gbìyànjú láti wo ohun tí ìmọ̀ abínibí jẹ́, àwọn ìṣòro tó ń dojúkọ ètò ìṣèlú Nàìjíríà pẹ̀lú ojú àmúwayé àwọn onímọ̀ àti àwọn ìbéèrè ìtanijí. Lẹ́yìn èyí ni a ṣe ìtúpalẹ̀ àṣàyàn àwọn ewì àpilẹ̀kọ Yorùbá mẹ́sàn-án ní ìbámu pẹ̀lú àfojúsùn wa nínú àpilẹ̀kọ yìí. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn onímọ̀ ló ti ṣiṣẹ́ lórí ìmọ̀ abínibí, àṣà, ìṣèlú Nàìjíríà àti ipa òǹkọ̀wé nínú ìdàgbàsókè àwùjọ gẹ́gẹ́ bí a ti ṣàgbéyẹ̀wò ìṣẹ́ wọn ní ṣisẹ̀-n-tẹ̀lé.

## Iṣé Àwọn Onímọ̀ Lórí Ìmọ̀ Abínibí, Ètò Ìṣèlú Yorùbá àti Nàìjríà

Àwọn onímọ̀ bí Ògúnṣínà (1988), Adéyẹmí (2005), àti Àlàbá (2011) ti ṣiṣẹ́ ìwádìí lórí kókó-ọ̀rọ̀ tó ní ṣe pẹ̀lú ìdàgbàsókè Nàìjíríà. Bákan náà, àwọn onímọ̀ lóríṣiríṣi ti ṣe àgbéyẹ̀wò lórí àṣà Yorùbá láìmẹ́nu ba ìwúlò rẹ̀ ní pàtó fún Nàìjíríà lápapọ̀. Ògúnṣínà (2013) àti Adébọ̀wálé (2014) tilẹ̀ ṣe àfọmọ́ ọ̀rọ̀ pé kí á ṣe ìlú kó gún, ààbò tó péye jẹ́ ìpìlẹ̀ pàtàkì tí a kò le fọwọ́ yẹpẹrẹ mú.

## Ìmọ̀ Abínibí àti Ìwúlò rẹ̀ nínú Ìṣèlú Àwùjọ/Orílẹ̀-èdè

Rajasekaran (1992:4) ṣàpèjúwe ìmọ̀ abínibí gẹ́gẹ́ bí "ìlànà ìmọ̀ tí ó di ti àwọn ènìyàn àwùjọ kan nípasẹ̀ ìrírí tí kò jẹ mọ́ ẹ̀kọ́ ilé-ìwé àti òye kíkún nípa àyíká inú àṣà wọn". Àròjinlẹ̀ onímọ̀ yìí fi hàn pé kì í ṣe inú ètò mọ̀-ọ́n-kọ-mọ̀-ọ́n-kà nìkan ni ìmọ̀ pin sí láwùjọ ẹ̀dá. Bákan náà ni Steiner (2008:9) wòye pé, "ìmọ̀ abínibí máa ń fún ni ní ìmọ̀ tí a nílò fún ìwàláàyè, ní pàtàkì jùlọ bó ṣe jẹ mọ́ ìbáṣepọ̀ àti ètò ọrọ̀-ajé tó lè mú àdínkù bá òṣì bí wọ́n bá polongo rẹ̀, tí wọ́n sì ṣe alàfibọ̀ rẹ̀ sí ìgbé ayé ìgbàlódé láwùjọ". Kókó tí a rí fàyọ nínú ìdúrówòye Steiner nípa ìmọ̀ abínibí ni pé kò sí àwùjọ tí kò nílò rẹ̀ fún ìbágbépọ̀ àti ìdágbàsókè ọrọ̀-ajé fún ìgbáyégbádùn ẹnìkọ̀ọ̀kan nínú ètò ìṣèlú orílẹ̀-èdè/ìlú. Ní èrò tirẹ̀, Olúmúyìwá (2014:4) sọ wí pé "ìṣinilọ́nà ni yóò jẹ́ bí a bá fẹ́ tẹ́wọ́gba oríkì kan pàtó fún ohun tí a mọ̀ sí ìmọ̀ abínibí nítorí pé ìtumọ̀-ọlọ́pọ̀-ẹ̀yà tó dá lórí àwùjọ kọ̀ọ̀kan ni a lè fún un". Àkíyèsí yìí tọ̀nà nítorí pé ìhà tí ẹ̀yà/agbègbè bá kọ sí oríṣiríṣi ìṣẹ̀lẹ̀/àyíká wọn ni yóò sọ ojú

àmúwayé àti irúfẹ́ oríkì tí wọn yóò fún ìmọ̀ abínibí. Èyí túmọ̀ sí pé ìmọ̀ abínibí jẹ́ èròjà tó sodo sínú bùba àṣà àti ìṣe ẹ̀yà kọ̀ọ̀kan.

Wàyí ò, a lè sọ pé ìmọ̀ abínibí, gẹ́gẹ́ bí orúkọ rẹ̀, jẹ́ àwọn ọ̀kan-ò-jọ̀kan bárakú ìmọ̀ aníyelórí tó jẹ́ àjogúnbá tí àwùjọ fi máa ń kọ́ ọmọ láti ìgbà èwe pẹ̀lú èròǹgbà/àfojúsùn pé irúfẹ́ ọmọ bẹ́ẹ̀ yóò lè dá ìpinnu adáńfó ṣe lọ́jọ́-iwájú. Nínú àṣà àti ìṣe, gẹ́gẹ́ bó ṣe jẹ mọ́ ẹ̀sìn, ìṣèlú, ètò ọrọ̀-ajé, ìdájọ́, ọdún ìbílẹ̀, iṣẹ́ abínibí, ẹ̀kọ́-ilé, ìbágbépọ̀ àti bẹ́e bẹ́ẹ̀ lọ ni ìmọ̀ àjogúnbá ti máa ń fara hàn jùlọ láwùjọ. Irúfẹ́ ìmọ̀ yìí kò ṣe é fi ọwọ́ rọ́ sẹ́yìn nínú gbogbo ìdáwọ́lé ènìyàn láyé. A lè sọ pé nípa *ìṣẹ̀ṣe/ìmọ̀ràn/kíkọ́/ìtọ́nisọ́nà/ìbáwí* ènìyàn ni a ti máa ń fi ìmọ̀ kún ìmọ̀, yálà nípa ti ẹ̀sìn, àṣà àti ìṣe, ìkọ́ṣẹ́ tàbí ẹ̀kọ́ mọ̀-ọ́n-kọ-mọ̀-ọ́n-kà. Abájọ tí Ifá, nínú Odù "Òtúá Méjì", fi sọ pé:

*Bí a bá jí*
*Ọgbọ́n ni ká máa kọ́ ara wa*
*Ká máa fàfẹ̀mọ́júmọ́ pilẹ̀ wèrè...*
- Abímbọ́lá (2006)

Ọládípọ̀ (2007:2) ṣe àlàyé lórí bí "Yorùbá ṣe máa ń fi ojú-inú wo àwọn àdìtú ayé, èyí tó jẹyọ nínú ohun àforírò wọn gbogbo". Àsọyé Ọládípọ̀ nípa Yorùbá àti ìgbé ayé wọn lórí ìlànà wíwá ọ̀nà àbáyọ sí ìṣòro jẹ́ òtítọ́ pọ́ńńbélé.

Àwọn èrò, ìgbàgbọ́ àti ìrírí ẹ̀dá lókè eèpẹ̀ ló máa ń para pọ̀ di àṣà, bẹ́ẹ̀ sì ni, inú àṣà ni a ti lè rí àrítọ́kasí ìmọ̀ abínibí. Nítorí àìní àkọsílẹ̀ ṣaájú dídé àwọn aláwọ̀ funfun, inú lítíréṣọ̀ alòhun lóríṣiríṣi ni ìmọ̀ abínibí Yorùbá sodo sí. Yorùbá ní ètò fún ohun gbogbo, wọ́n sì mọ ẹ̀tọ́ gẹ́gẹ́ bó ṣe hàn nínú ìlànà ìṣèlú wọn (Jéjé & Dáramọ́lá, 1975). Ọ̀nà méjì ni a lè gbà ṣe àlàyé lórí ìmọ̀: ìmọ̀ gẹ́gẹ́ bí àbùdá gbogbogbòò fún gbogbo aráyé àti ìmọ̀

abínibí ẹ̀yà kọ̀ọ̀kan. Ifá nínú Odù "Òtúúrúpọ̀n" fi ìdí èyí múlẹ̀ pé:

*Ológbọ́n kan ò ta kókó omi sétí aṣọ*
*Àwọn ọ̀mọ̀ran wọn ò mọye eèpẹ̀ ilẹ̀*
*Ká mọ̀ràn mọ̀ràn,*
*Ká mọ pọ́nna pẹ̀lú;*
*A diá fún ọlọ́gbọ́n méjì*
*Tí ó fọwọ́ araa rẹ̀ tún 'wà*
*araa rẹ̀ ṣe ….*
- Abímbọ́lá, (2006)

Ifá jẹ́ kí á mọ̀ pé bí ó ti wù kí ènìyàn kan gbọ́n tàbí mọ̀ràn tó, ó ní ibi tí ọgbọ́n ẹni náà mọ. Fún ìdí èyí, ká gbìmọ̀ràn pọ̀, ká fi ọgbọ́n kún ọgbọ́n ló lè ran *ẹnìkọ̀ọ̀kan, ẹbí, ìlú* tàbí *orílẹ̀-èdè* lọ́wọ́ fún ìgbọ́raẹniyé, ìdàgbàsókè àti ìtẹ̀síwájú. Ìmọ̀ abínibí ní ṣe pẹ̀lú àbùdá *ìwáṣẹ̀/ìṣẹ̀dálẹ̀/ìṣẹ̀ṣe* ìlú tàbí ẹ̀yà kọ̀ọ̀kan àti ọ̀nà tí wọn ń gbà ṣe àmúlò rẹ̀ fún ìdàgbàsókè wọn. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ló ní àǹfààní láti kópa nínú ètò ìṣèlú àbáláyé Yorùbá lọ́nà kan tàbí òmíràn - yálà gẹ́gẹ́ bí Ọba, Olóyè, Bọ̀rọ̀kìnní, Ẹlẹ́gbẹ́jẹgbẹ́ (ọ̀dọ́ ìlú) tàbí Olóríjorí, (lọ́mọdé/lágbà, lọ́kùnrin/lóbìnrin). Bákan náà, ọ̀tọ̀ ni ipò àti ipa àwọn Bàbálóòṣà/Ìyálóòṣà, àwọn ẹ̀ṣọ́ ìlú, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ nínú ètò ìṣèlú ilẹ̀ Yorùbá. Ìlànà ìṣèlú Yorùbá jinlẹ̀, ọgbọ́n-ìmúṣẹ́ṣe wọn sì tún jẹ́ ọ̀nà kan tí ètò ọrọ̀-ajé wọn fi gbòòrò Akínjógbìn & Àyándélé, 1980:130). Ètò ìbágbépọ̀ Yorùbá fún ẹnìkọ̀ọ̀kan ní òye pé, oníkálukú ló ní ààyè àti ipa tí ó yẹ kí ó kó fún ìtẹ̀síwájú ìlú (Adéoyè, 2005). Nípa báyìí, kíkọ-ibi-ara-sí ríran àwọn tó wà ní ìgbọ́nnu ètò ìṣèlú lọ́wọ́ máa ń jẹ́ ìwúrí.

Èyí fi ìyàtọ̀ hàn láàrin bí áwọn ènìyàn ṣe máa ń tú yáàyá, tú yààyà fún ìmúdúró-ṣọ̀kan nínú ìṣèlú àbáláyé ṣùgbọ́n ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ ènìyàn ló máa ń dágunlá pẹ̀lú ìhà kò-kàn-mí sí ìjọba tiwa-n-tiwa

(*alágbádá*). Ìmọ̀ abínibí Yorùbá tan ìmọ́lẹ̀ kedere sí ìlànà ìṣèlú wọn lọ́nà tí *olórí fi mọ orí, (Ọba/àwọn Ìjòye) tí onírù sì mọ ìrù (àwọn ará ìlú).* Bí àpẹẹrẹ, nínú ìṣẹ̀ṣe ajẹmọ́-ìṣèlú Yorùbá, ìyà tó dógbin wà fún ìrúfin ẹ̀ṣẹ̀ ajẹmọ́-ìṣèlú. Àwọn Ògbóni/Òṣùgbó/Awo-Ọpa (Ìjẹ̀bú), Tánràn (Èkó/Ìjẹ̀bú), Awo-Ọpa, ni wọn dúró bí adájọ́. Yorùbá lọ́gbọ́n lórí, wọ́n ní ìmọ̀, wọ́n sì lóye tó ń ràn wọ́n lọ́wọ́ nínú ìgbésẹ̀ wọn gbogbo. Èyí jẹ́ ẹ̀rí pé ṣaájú kíkọ òfin ìṣèlú Nàìjíríà sílẹ̀, ká hùwà tó bá òfin mu kò ṣàjèjì sí ọmọ Yorùbá. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé òfin wà ní Nàìjíríà tí ètò ìdájọ́ sì wà, àwọn òfin yìí kò múlẹ̀ fún ìsọ̀rí àwọn ènìyàn kan. Àwọn òwe wọ̀nyí tún jẹ́ ẹ̀rí nípa ìwulò ìmọ̀ abínibí nínú ìlàná ètó ìṣèlú Yorùbá:

(i). Ìdálùú ni ìṣèlú, eégún níí gbowó òde Òṣogbo, òòṣà níí gba ti ibòmíràn.

(ii). Àìfini peni, àìfèèyàn pèèyàn, tí í mú ará oko ó sán bàǹtẹ́ wọ̀lú.

(iii). Ọba/Ààrẹ ń pè ọ́, ò ń dífá, bí Ifá bá fọre tí Ọba Ààrẹ ò fọ ‘re ńkọ́?

(iv) Àgbà kò sí, ìlú bàjẹ́, baálé ilé ku; ilé dahoro.

(v) Ó kù dẹ̀dẹ̀ ká gbéwì d’Ọ́yọ̀ọ́, Oba Jáayín tẹ́rí gbaṣọ.

Òwe kìnní àti ìkejì jẹ ká mọ̀ pé, ìlànà tàbí òdiwọ̀n wà fún ètò ìṣèlú Yorùbá, òwe kejì àti ìkẹta ṣe àfihàn ìpín onípòjipò àti ojúṣe àwọn abẹnugan fún ìmúdúró-ṣọ̀kan ìlú; nígbà tí òwe karùn-ún ṣe àfọ̀mọ̀ lórí pé kò sí ẹni tó kọjá òfin tàbí ìbáwí tó bá ṣe aṣemáṣe tó lòdì sí àgbékalẹ̀ àwùjọ. Èyí tọ́ka sí pé àbùdá àkóyawọ́, nípa àmúlò ìmọ̀ abínibí wà nínú ìlànà ètò ìṣèlú/ìdájọ́ Yorùbá.

Ọ̀kan-ò-jọ̀kan ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ Yorùbá nípa ìfiwàwẹ̀dá inú àlọ́-onítàn, ewì alohùn, ìtàn ìwáṣẹ̀ àti òwe fi àpẹẹrẹ àbùdá ìṣèlú àbáláyé Yorùbá pẹ̀lú ìmọ̀ abínibí hàn. Lóde-òní, ọ̀pọ̀ ọmọ Nàìjíríà ni kò fi bẹ́ẹ̀ kọ ibi ara sí ètò àti ojúṣe tó lè mú kí ìṣèlú kẹ́sẹ̀ járí fún ìmúdúró-ṣọ̀kan. Ohun tó jẹ ọ̀pọ̀ lógún ni àǹfààní tí wọ́n lè jẹ nínú ìṣèlú. Nípa àfiwéra yìí, àkíyèsí wà pé ìmọ̀ ní gbogbo ẹ̀yà yòówù kó jẹ́ ṣe pàtàkì. Nípa pàtàkì ìmọ̀, Ọládípọ̀ (2002:67) sọ pé:

> *Knowlegde is crucial to human survival and flourishing. It is one of the reasons by which human beings seek to master their environment and regulate their social interactions. Indeed, without knowledge, human beings would hardly be better than brutes.*
>
> Ìmọ̀ ṣe pàtàkì púpọ̀ fún wíwà láàyè àti gbígbilẹ̀ ènìyàn. Ó jẹ́ ìdí kan tí àwọn ènìyàn fi máa ń ṣe àwárí/ìkáwọ́ àwùjọ wọn àti láti jẹ́ kí ètò ìbára-ẹni-sọ̀rọ̀ láwùjọ se déédéé, láìsí ìmọ̀, ó ṣeé ṣe kí ẹ̀dá ènìyàn má fi bẹ́ẹ̀ sàn ju ẹran líle lọ.

Ìmọ̀ abínibí àwùjọ tí ènìyàn wà jẹ́ ọ̀kan lára ìmọ̀ tí ènìyàn lè kọ́kọ́ múlò láyé. Lára àbùdá ìmọ̀ abínibí Yorùbá, pàápàá èyí tó jẹ mọ́ ìṣèlú ni: *ìfiwàjoyè, àṣẹ Ọba, onípòjipò, ẹlégbéjẹgbé, ìforíkorí, ìpàdé àlàáfíà, ààbò tó péye, ìpínṣẹ́ṣe, ìsìnlú, ètò ọrọ̀-ajé, ìṣẹ̀ṣe* àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Àgbékalẹ̀ ìlànà ìṣèlú Yorùbá fi hàn pé ìpàdé ìjíròrò fún àlàáfíà máa ń wáyé, bí ọ̀rọ̀ bá ṣe bí ọ̀rọ̀. Ilésanmí (1991:6) tilẹ̀ sọ pé "ìṣèlú ni ààrin gbùngbùn àṣà Yorùbá." Nítorí náà, àmúlò ìmọ̀ abínibí pẹ̀lú ìwà ọmọlúàbí fún

ìṣèlú lọ́nà tó gún régé dé àyè kan jẹ́ ara ẹwà ìṣèlú Yorùbá (Adéoyè 2005:276). A lè sọ wí pé, ètò agbo-ilé Yorùbá ni ìpilẹ̀ṣẹ̀ ètò àdúgbò, ti àdúgbò ni ìpilẹ̀ṣẹ̀ ètò ìlú, lórí ètò wọ̀nyí ni Yorùbá gbé ètò ìṣèlú rẹ̀ lé gẹ́gẹ́ bí *orílẹ̀-èdè* kan tó ní Ọba kan ṣoṣo láyé Odùduwà. Ní báyìí tí a ti ṣe àgbéyẹ̀wò ipa pàtàkì ìmọ̀ abínibí nínú ètò ìṣèlú, ó ṣe pàtàkì kí á wo bí ìmọ̀ ti jẹyọ nínú àṣà àti ipa rẹ̀ nínú ìṣèlú.

## Àṣà Yorùbá àti Ìwúlò rẹ̀ Nínú Ètò Ìṣèlú Nàìjíríà

Gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ àwọn onímọ̀ àwùjọ àdáyébá, àṣà jẹ́ àárin gbùngbùn ohun àforíírò ẹ̀dá. Àṣà lè máa "dàgbà" tàbí kó di akúrẹtẹ̀ nípa dídúró sí ojú kan gbári láìsí ìtẹ̀síwájú. Bí àṣà bá ní ìdàgbàsókè, yóò ran àwùjọ. Ìdí ni pé àwùjọ dúró fún àwọn ènìyàn kan nígbà tí àṣà wọn ní ṣe pẹ̀lú ìhùwàsí wọn. (wo Srivastava, 2013:10). Nínú ètò ìṣèlú Yorùbá, ìgbèríko ló sún mọ́ àwọn ènìyàn jùlọ gẹ́gẹ́ bí ìjọba ìbílẹ̀ ti yẹ kó sún mọ́ àwọn ará ìlú nínú ètò ìjọba tiwa-n-tiwa.

Bọ́lájí (1981:iii), fi ìdí èyí múlẹ̀ pé:

> *It is commonly agreed that village life is nearest to the life of the ancestors of any people since villagers stick to the tradition for as long as possible before they reluctantly bow to the forces of modernity. The village is compact enough to ensure that one person's business is the business of all.*
>
> Ó jẹ́ ohun àfẹnukò lé lórí pé ìgbé ayé abúlé/ìletò ló sún mọ́ àwọn ìṣẹ̀run ẹni ẹ̀yà yòówù níwọ̀n ìgbà tí àwọn ará abúlé tẹra mọ́ àṣà ní gbogbo ìgbà tó bá ṣeé ṣe kó tó di

> pé wọn fi ìlọ́ra jọ̀wọ́ ara wọn fún ìṣe ọ̀làjú. Abúlé wà nífaramọ́ra tó bẹ́ẹ̀ tí ó jẹ́ pé ohun tó bá kan ẹnìkan kan gbogbo ènìyàn ibẹ̀ gbọ̀gbọ̀n.

Gẹ́gẹ́ bí àlàyé Bọ́lájí (1981), ìlànà ìṣèlú tó rọ̀gbọ̀kú lé ìmọ̀ abínibí Yorùbá jẹ́ àbùdá ètò ìṣèlú ajẹmọ́-ìgbèríko títí di òní. Èyi sì jẹ́ ọ̀kan lára àbùdá ìmúdúró ètò ìṣèlú wọn. Bọ́lájí fojú inú wo èrò àti ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ Yorùbá lọ́nà tó ń gbà ràn wọ́n lọ́wọ nípa ọgbọ́n àtinúdá wọn ní ìbámu pẹ̀lú bí àwùjọ wọn ṣe rí, èyí tó wúlò fún ìmúṣọ̀kan ìlú/orílẹ̀-èdè. Àlàyé Ìṣọ̀lá (2010:29) nipa àṣà fi hàn pé, "Àṣà jẹ ọ̀nà àrà tí Olódùmarè gbà to àwọn ìsọ̀rí tàbí àgbáríjọ̀ ènìyàn kọ̀ọ̀kan pọ̀ ní gbogbo àgbáyé. Rodney (2009:38) náà jẹ́rìí sí èyí pé, àṣà jẹ́ ìgbé ayé àwọn ènìyàn tó dá lórí jíjẹ, ìwọṣọ, ìṣọwọ́rìn àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ pẹ̀lú àfikun pé iṣẹ́-ọna orílẹ̀-èdè bí Egypt, Sudan àti Ethopia jẹ́ gbajúgbajà ní gbogbo àgbàyé. Ẹ̀yà kọ̀ọ̀kan tòhun ti àbùdá àrà ọ̀tọ̀ ajẹmọ́-èrò àti ìmọ̀ abínibí tí wọn ń lò láti ṣètò ìgbé ayé wọn" Ó fi kún ọ̀rọ̀ rẹ̀ pé ó ṣe pàtàkì láti ní ìmọ̀ kíkún nípa àṣà fún ìró-ara-ẹni-lágbára àti fún ìtanijí àwọn ènìyàn àwùjọ. Ìdàpọ̀ oríṣiríṣi ẹ̀yà tó di Nàìjíríà lónìí ṣe àfihàn ìjọra díẹ̀ nípa àbùdá ìṣèlú láàrin wọn.

## Akitiyan Ìdàpọ̀ Oríṣiríṣi Ẹ̀yà tó di Nàìjíríà láti Ọwọ́ Ìjọba Amúnisìn

Ìyàtọ̀ tó wà nínú ìlànà ìṣèlú Yorùbá àti ti àwọn ẹ̀yà mìíràn wáyé nítorí ìjọba amúnisìn lábẹ́ àkóso Lord Lugard so àwọn ẹ̀yà mẹ́tẹ̀ẹ̀ta tí wọ́n tóbi jù ní Nàìjíríà: Hausa, Igbo, Yorùbá àti àwọn ẹ̀yà yòókù papọ̀. Aṣíwájú ló tún jẹ́ gẹ́gẹ́ bí asojú ìjọba ilẹ̀ Gẹ̀ẹ́sì. Aya Lugard tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Florence Shaw ló sọ àwọn ẹ̀yà tí ọkọ rẹ̀ so papọ̀ ní "Niger-Area" nígbà náà, kí àgékúrú àpólá-

orúkọ yìí tó wá di "Nigeria" tí ó ń jẹ́ lónìí. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé wọ́n kojú ìpèníjà, ipa mánigbàgbé ni William Macgregor (alákòóso Èkó), Ralph Moor (alákòóso gúsù), àti Fredrick Lugard (alákòóso àríwá) kó láti fi Nàìjíríà sí abẹ́ àkóso ìjọba ilẹ̀ Gẹ̀ẹ́sì ní ọdún 1900. Èròǹgbà láti máa ṣàkóso ètò ìṣèlú àti ọrọ̀-ajé nípasẹ̀ àwọn olórí ìlú ní Nàìjíríà ni Lugard fi so ẹ̀ya bí ọ̀tàlérúgba ó dín mẹ́wàá (250) papọ̀ ní ọdún 1914 (Ọláníyan & Àlàó, 2003:1). Àyọrísí àsopọ̀ tó bí ìtàpórógan nínú ètò ìṣèlú Nàìjíríà nípasẹ̀ àìná-án-ní àbùdá ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ tó ya àwọn ẹ̀yà wọ̀nyí sọ́tọ̀ ló ń farahàn látẹ̀yìnwá. Àkíyèsí wà pé láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀, pàápàá lẹ́yìn òmìnira ló ti dà bí ẹni pé ohun gbogbo kò fararọ nínú ìṣèlú Nàìjíríà. Ojú àmúwayé àwọn onímọ̀ àti àwọn akéwì àpilẹ̀kọ Yorùbá jẹ́ ẹ̀rí sí ìdí abájọ ìbẹ̀rẹ̀ àti àyọrísí ìṣòro ìṣèlú Nàìjíríà.

## Àgbéyẹ̀wò Iṣẹ́ Àwọn Onímọ̀ Nípa Ètò Ìṣèlú Nàìjíríà

Akíntúndé (1967:5) wòye lórí *ogun* tó ń bá Nàìjíríà fínra lọ́wọ́ pé láti ìpìlẹ̀ lọ̀rọ̀ ti wọ́ wá. Ìjọba ilẹ̀ Gẹ̀ẹ́sì tí wọ́n fún Nàìjíríà ní *òmìnira* ní ìpìlẹ̀ ìṣèlú pẹ̀lú ọrọ̀-ajé tó dára, èyí tí orílẹ̀-èdè yìí kò ní ṣaájú gbígba òmìnira. Lákọ̀ọ́kọ́, ètò ìṣèlú ìjọba ilẹ̀ Gẹ̀ẹ́sì àti ti Amẹ́ríkà dúróore lórí ètò ọrọ̀-ajé tó rẹ́sẹ̀ múlẹ̀ gidigidi. Nítorí náà, wọ́n ní àǹfààní àti dá ṣè ìpinnu lórí ọrọ̀-ajé orílẹ̀-èdè wọn láìsí alàgàta. Ṣùgbọ́n, lẹ́yìn òmìnira, ọ̀kan pàtàkì lára ìpèníjà tí Nàìjíríà kojú ni ìmúnisìn ajẹmọ́ ọrọ̀-ajé àti ìṣèlú láti ọ̀dọ̀ àwọn aláwọ̀ funfun àti àwọn ọmọ bíbí Nàìjíríà tí wọ́n jẹ́ olóṣèlú gan-an. Láti ìgbà náà títí di àsìkò yìí ni ìdàgbàsókè ọrọ̀-ajé Nàìjíríà ti ń mẹ́hẹ bọ̀ títí di òní. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé pẹ̀lú ìwúrí ni wọ́n fi gba ìjọba tiwa-n-tiwa lásìkò ìjìjàgbara, ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn tó

ń darí ìjọba ni ilẹ̀ Adúláwọ̀, Éṣíà, àti gúsù Amẹ́ríkà ló di *má-gbó-mi-lẹ́nu* pẹ̀lú ìjẹgàbalé àwọn ènìyàn wọ́n lórí (Payne & Nassar, 2006:205).

Èyí fi hàn pé èrò àwọn orílẹ̀-èdè tó ṣẹ̀ṣẹ̀ ń dìde lágbàáyé nípa ìjọba tiwa-n-tiwa yàtọ̀ sí ìhà tí àwọn ènìyàn kọ sí i ní àwọn orílẹ̀-èdè tó ti gòkè àgbà. Jíjẹ́ ọmọ orílẹ̀-èdè àti èròǹgbà ìmúdúró-ṣọ̀kan orílẹ̀-èdè ajẹ́mọ́-àṣà púpọ̀ túmọ̀ sí wíwó odi ẹ̀yàmẹ̀yà palẹ̀ láti dí ọ̀kan níbi tí ẹ̀yà kan kò ti jẹ́ gàba lórí òmíràn (wo Ifidon, 2003:170). Ìfarahàn ìtàpórógan nítorí ìrírí *ìwà ìjẹgàba*, *jẹgúdújẹrá*, *àìṣẹ̀tọ́*, *ìrẹ́jẹ*, *ẹléyàmẹ̀yà*, *ìgbénipa*, *àìlákòóyawọ́* àwọn olóṣèlú àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ máa ń jẹ́ kí àwọn ènìyàn fi ojú tẹ́ńbẹ́lú ìjọba tiwa-n-tiwa bí èyí tẹ̀wọ̀n/ni àmúyẹ tí kò/tó nínú ìgbéléwọ̀n wọn nígbà mìíràn. Nínú àkíyèsí rẹ̀ lórí bí ìjọba tiwa-n-tiwa ṣe máa ń ṣe apa kan jànmá, Baradat (2006:63) sọ pé:

> *There are almost 220 national constitutions in the world today, and almost all of them claim to be democratic. Democracy is currently a very popular term, but people have not always found it attractive. For a time, the ancient Greek practiced direct democracy, in which all male adult citizens voted on governmemt policy. Gradually, however, that system evolved into a more authoritarian form, and democracy lost public acceptance. To Plato, for example, democracy meant ochlocracy, or rule by the mob.*
>
> Ó fẹ́rẹ̀ tó okòó-lé-lé-lúgba òfin ìṣàkóso orílẹ̀-èdè tó wà lágbàáyé lónìí, gbogbo

> wọn ló sọ pé wọ́n faramọ́ ètò ìjọba onípinnu-tọ̀pọ̀-ènìyàn-ló-tọ̀nà. Lọ́wọ́lọ́wọ́ ìjọba tiwa-n-tiwa jẹ́ ìpèdè tó gbajúgbajà, ṣùgbọ́n àwọn ènìyàn kò fi gbogbo ara gbà á gẹ́gẹ́ bí èyí tó wuyì. Fún ìgbà díẹ̀, Gíríìkì àtijọ́ ṣàmúlò ìjọba tiwa-n-tiwa tààrà, nínú èyí tí gbogbo àgbà lọ́kùnrin tó jẹ́ ọmọ orílẹ̀-èdè ti máá ń dìbò lórí ìlànà ìjọba. Ṣùgbọ́n, kẹ̀rẹ̀kẹ̀rẹ̀ bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ ìlànà yìí yípadà di ti aláṣẹ-má-gbó-mi-lẹ́nu, ìjọba tiwa-n-tiwa sì pàdánù ìtẹ́wọ́gbà ará ìlú. Lérò Plato, gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, ìjọba tiwa-n-tiwa túmọ̀ sí oníjàǹdùkú tàbí ìṣèlú láti ọwọ́ àwọn jàǹdùkú.

Láìsí àníàní, àwọn orílẹ̀-èdè alágbára lágbààyé ń fọnrere pé kí orílẹ̀-èdè kọ̀ọ̀kan tẹ́wọ́gba ìṣèlú ìjọba tiwa-n-tiwa. Bí á bá fi ojú inú wo ọ̀rọ̀ Baradat (2006) yìí, lóòótọ́ ni ìjọba tiwa-n-tiwa gbajúgbajà, ṣùgbọ́n ọ̀pọ̀ nínú àwọn tó jẹ́ alákóso àti àwọn amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ wọn ni ìṣesí àti ìgbésẹ̀ wọn jọ ti jàǹdùkú; pàápàá ní ilẹ̀ Nàìjíríà. Èyí ni a lérò pé ó jẹ́ kí ó nira fún àwọn ọmọ orílẹ̀-èdè yìí láti fi ọkàn tán ìṣèlú ìjọba tiwa-n-tiwa dénúdénú gẹ́gẹ́ bó ti ṣẹlẹ̀ rí ní ilẹ̀ Gíríìkì tó jẹ́ orísun ìjọba tiwa-n-tiwa. Àmọ́, pẹ̀lú ìfọwọ́sowọ́pọ̀ ará ìlú àti àwọn alákòóso láti yanjú ìṣòro ajẹmóṣèlú, a kò le fi ìjọba tiwa-n-tiwa wé ti ológun láéláé.

Pẹ̀lú àkíyèsí, ijọba tiwa-tiwa àkọ́kọ́ ọdún 1960 - 1966 jẹ́ olómìnira lóòótọ́, ṣùgbọ́n ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ ọmọ orílẹ̀-èdè yìi ni wọn ń rá mù-ún-ùn nínú ìṣẹ́ òun òṣì. Bí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa ipa ètò-ọrọ̀-ajé nínú ìṣèlú, kì í ṣe ọ̀rọ̀ epo bẹntiróòlù nìkan, bí kò ṣe ìsọdoníṣòwò-ìṣẹ̀dá-nǹkan-jáde gẹ́gẹ́ bó ṣe jẹ́ òpómúléró ètò ọrọ̀-ajé/ìṣèlú àwọn orílẹ̀-èdè tó ti lààmìlaaka lágbààyé. Èyí túmọ̀ sí

pé ètò a-jẹmọ́-ìṣèlú kò yẹ kó ṣaájú ìgbéfúkẹ́ ọrọ̀-ajé tàbí ìyípadà àrà-ọ̀tọ̀-ajẹmọ́-ìṣe-nǹkan-jáde tó lè mú kí àǹfààní wà láti pèsè fún gbogbo ọmọ orílẹ̀-èdè yìí. Nípa òfin àti ìlànà àgbékalẹ̀ rẹ̀, Ọ̀wọ̀adé (1988:158) sọ pé "ìṣòro ìjọba alápapọ̀ dá lórí ìlànà ìṣèlú gan-an àti òfin tó rọ̀ mọ́ ìṣàkóso pẹ̀lú ọrọ̀-ajé àti ìṣèlú orílẹ̀-èdè". Wàyí ò, àwọn ìbéèrè to ṣe kókó nípa ìjọba tiwa-n-tiwa tí Nàìjíríà tẹ́wọ́gbà nìwọ̀nyí:

(i) Ǹjẹ́ títẹ́wọ́gba ìlànà ìṣèjọba ilẹ̀ òkèèrè lè fún wa ní ìrírí tó kún tó nípa ìṣèlú láwùjọ Nàìjíríà?
(ii) Kí ni àwọn akùdé tó ń wáyé lemọ́lemọ́ nínú ètò ìṣèlú ìjọba tiwa-n-tiwa, èyí tó nílò àfikún ìmọ̀ abínibí?
(iii) Ǹjẹ́ títẹ́wọ́gba ìlànà ìṣèlú ilẹ̀ òkèèrè ní àbùdá, ìmọ̀, òye àti àmúyẹ tí ìrírí rẹ̀ bá àbùdá ìṣèlú àbáláyé àwọn ẹ̀yà Nàìjíríà mu?
(iv) Ǹjẹ́ ìmọ̀ abínibí tó jẹ́ *ohun àjogúnbá iyebíye* tó wà ní ìbámu pẹ̀lú ìṣèlú àtayébáyé ẹ̀yà kọ̀ọ̀kan kò ní dẹ̀gbẹ́ bí a bá tẹra mọ́ ìlànà ìṣèlú ilẹ̀ òkèèrè nìkan tó lè má ṣe *àwòtán ìṣòro àtọwọ́dá* àtọdúnmọ́dún tó ń bá Nàìjíríà fínra?
(v) Ojú wo ni àwọn akéwì àpilẹ̀kọ Yorùbá fi wo ṣíṣe àmúlò ìmọ̀ abínibí nínú ìṣèlú ìjọba àbáláyé Yorùbá àti tiwa-n-tiwa lọ́nà tí àbùdá/ìlànà ìṣèlú méjèèjì fi jẹ́ èyí tí kò ta ko ara wọn

Láìsí àníàní, pẹ̀lú àwọn ìbéèrè tó pè fún ìdáhùn wọ̀nyí, ó hàn gbangba pé *àlàfo* kan tó ṣe pàtàkì wà fún Nàìjíríà láti dí. Èyí yóò mú kí ètò ìṣèlú àti ọrọ̀-ajé rẹ̀ tó lè múnádóko/figagbága pẹ̀lu ìdàgbàsókè tó mọ́yán lórí bí ti ilẹ̀ òkèèrè. Láti inú ìwòye, àwọn òǹkọ̀wé alátinúdá náà máa ń lo iṣẹ́-ọnà wọn láti ṣe atótónu lórí àwọn ìṣòro ìṣèlú orílẹ̀-èdè pẹ̀lú àbá lóríṣirísi.

## Ipa Àwọn Òǹkọ̀wé Alatinúdá Nínú Ìṣèlú Orílẹ̀-Èdè

Ní ìwòye àwọn onímọ̀, ipa pàtàkì ni àwọn oníṣẹ́-ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀ ń kó nínú ìdàgbàsókè àwùjọ, pàápàá nípa ọ̀rọ̀-ìṣèlú àti ọrọ̀-ajé. Ìṣọ̀lá (1991:78) ṣe àlàyé pé, "òtọ̀ọ̀tọ̀ ni àwọn òǹkọ̀we alátinúdá ṣe àgbékalẹ̀ Ọba aládé Yorùbá gẹ́gẹ́ bí olórí tó lágbára nípa ìṣèlú, síbẹ̀, ètò ìṣèjọba agbájúmọ́-ìdẹ̀rùn–ará-ìlú jẹ́ kókó kan bàbàrà tó múmú láyà àwọn lọ́balọ́ba". Èyí tọ́ka sí pé pàtàkì nínú ojúṣe Ọba Yorùbá kọ̀ọ̀kan ni ìdẹ̀rùn àwọn ará ìlú rẹ̀. Ní ìdàkejì ẹ̀wẹ̀, Douglas (2012:23) sọ pé, "nínú ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìpèníjà tó dojú kọ àwùjọ Nàìjíríà lóde-òní, èyí tó jẹ́ olúborí ni bíbàkù àwọn aṣaájú òṣèlú láti ṣètò ìlànà ìṣèlú alákòóyawọ́; èyí tó yẹ kí àwọn ọmọ orílẹ̀-èdè jẹ́ àfojúsùn àwọn adarí. Nínú èrò tirẹ̀ lóri ọ̀kan pàtàkì nínú ipa tí lítíréṣọ̀ ń kó nínú ọ̀rọ̀ ìṣèlú, Bestman (1991:56) ṣàlàyé pé:

> *...African literature is obsessively political and polemical in character, it captures and reveals graphically the crises in a developing world... by identifying the socio-political determinants of our present anguish.*
>
> *Lítíréṣọ̀ ilẹ̀ Adúláwọ̀ kún fún ọ̀rọ̀ ajẹmọ́-ìṣèlú pẹ̀lú àbùdá ìtàpórógan/ìfẹ̀hónúhàn, ó ṣàkótán àti àfihàn àwòrán rògbòdìyàn ní orílẹ̀-èdè to ṣẹ̀ṣẹ̀ ń dìde... nípa títọ́ka sí ìrora/ìnira tí à ń fojú winá rẹ̀.*

Àkíyèsí Bestman (1991) yìí jẹ́ òòtọ́ pọ́nńbélé nítori pé ṣaájú òmìnira orílẹ̀-èdè Adúláwọ̀ kọ̀ọ̀kan ni ìjìjàgbara fún òmìnira ti jẹ́ ẹ̀dùn ọkàn tí tolórí-tẹlẹ́mù gbárùkù ti, títí tí àwọn aláwọ̀ funfun fi ṣíwọ́ ìjẹgàba. Ipa takuntakun ni àwọn òǹkọ̀wé

kó ṣaájú òmìnira tí wọ́n sì tún ń kó lẹ́yìn òmìnira. Èrèdí èyí ni pé ìlànà ìṣèlú ìjọba tiwa-n-tiwa àti ètò ọrọ̀-ajé kò tí ì fi ẹsẹ̀ múlẹ̀ tó bó ti tọ́ àti bó ti yẹ ní àwọn orílẹ̀-èdè Adúláwọ̀ aǹbèlèǹtàsé pé àwọn ará ìlú yóò rí èrè ìjọba tiwa-n-tiwa jẹ. Fún ìdí èyí, a lè béèrè pé ǹjẹ́ ìdánilójú wà pé ìjọba tiwa-n-tiwa pegedé ju ìlànà ìṣèjọba àbáláyé lọ.

Ògúnṣínà (1998: 89) náà ṣe àlàyé pé "ojú tí àwọn òǹkọ̀wé Yorùbá fi ń wo àwùjọ láti ìgbà dé ìgbà yàtọ̀ sí ara wọn, èyí tó dá lórí kókó ohun tó bá ń ṣẹlẹ̀ ní sáà kan". Ó tọ́ka sí i pe "ní ọdún 1960 sí 1970 ni Ọládẹ̀jọ Òkédìjí, ògúnná gbòǹgbò òǹkọ̀wé Yorùbá kan, ti ṣe àkíyèsí pé "àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ ti kọjá "ìwàásù" gẹ́gẹ́ bí àwọn kókó-ọ̀rọ̀ àwọn ìwé àpìlẹ̀kọ Yorùbá ìṣaájú ti fi hàn". Owólabí (2001:574) náà tọ́ka sí àgbékalẹ̀ Fágúnwà nípa ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ àwùjọ Yorùbá nínú èyí tó ti fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé "àarin gbùngbùn ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ Yorùbá ni ọgbọ́n tó níye lórí pẹ̀lú ọ̀wọ̀ pàgọ́ sí". Owólabí (2001) yòǹbó ọ̀nà àrà tí Fágúnwà gbà gbé àwọn ìwé ìtàn-àròsọ rẹ̀ kalẹ̀ láìtako ọ̀làjú lọ́nà tí ó fi lè rọrùn láti yanjú ìṣòro àwùjọ pẹ̀lú àmúlò ìmọ̀ abínibí Yorùbá. Lórí ètò ìṣèlú Nàìjíríà, àwọn òǹkọ̀wé Yorùbá ti fi ọgbọ́n inú, iyè ikùn, àti àtinúdá tó péye ṣàgbékalẹ̀ ọ̀kan-ò-jọ̀kan kókó-ọ̀rọ̀ ajẹmọ́ṣèlú nínú iṣẹ́-ọnà wọn. Nínú àkíyèsí rẹ̀ nípa ipò *ẹgẹrẹmìtì* tí Nàìjíríà wà, Adéyẹmí (2005:139) sọ pé, "ọ̀rọ̀ sùnnùkùn ni ọ̀rọ̀ ìṣọ̀kan orílẹ̀-èdè yìí àti ipa tí lítíréṣọ̀ Yorùbá ń kó, ojú sùnnùkùn ló yẹ ká fi wò ó." Pẹ̀lú gbogbo àkíyèsí àti àsọyé àwọn onímọ̀ wọ̀nyí lórí ipa òǹkọ̀wé àti ipò tí ọ̀rọ̀ ìṣèlú Nàìjíríà dé dúró, ó ṣe é ṣe kí ipa rere ti ibi ojú àmúwayé wọn jáde bí ìjọba bá gbé ìgbésẹ̀ tó yẹ. Ẹ̀rí láti inú àgbéyẹ̀wò ewì àpilẹ̀kọ Yorùbá fihàn pé

kò sí àríyànjiyàn nínú àwíjàre àti àròjinlẹ̀ àwọn akéwì lórí ipò tí ìṣèlú àti ọrọ̀-ajé Nàìjíríà wà.

## Àṣàrò àwọn Akéwì Àpilẹ̀kọ Yorùbá lórí Ipò Ìṣèlú àti Ìdájọ́ ní Nàìjíríà

Ẹyọ akéwì kan sí méjì kò le kógo já lórí ohun tí a fẹ́ gbé yẹ̀wò ni a ṣe ṣe àṣàyàn àwọn ewì àpilẹ̀kọ Yorùbá mẹ́sàn-án tó ní kókó-ọ̀rọ̀ ajẹmóṣèlú pẹ̀lú ìmọ̀ abínibí nínú. A ṣe àfiwéra àwíjàre àti àṣàrò àwọn akéwì lórí ìṣèlú Nàìjíríà láti wo ojú àmúwayé wọn. Láìjẹ́ orílẹ̀-èdè ìjọba olómìnira, àwùjọ kan kò le ní àlàáfíà àti ìtẹ̀síwájú. Ọládàpọ̀ (1973:59) nínú, *Àjọ̀dún òmìnira,* ròyìn ìdùnnú tó gbàlú-gboko kan lẹ́yìn ọdún 1960 tí Nàìjíríà di orílẹ̀-èdè olómìnira pé:

*...A dúpẹ́, a tọpẹ́ dá*
*Àjọ̀dún wọ̀lú dé, tá a wá lómìnira*
*Tá a rara wa tán: Tá a tún dọmọ*
*Ààbọ̀ ìlú rara rẹ̀, tó dọ̀tọ̀tọ̀*
. . .
*Ṣùgbọ́n ṣá: Olówó ẹrú kan kì í fẹ́ kẹ́rú ó sá*
*Olówó ìwọ̀fà kan kì í fẹ́ kó bọ́ lóko ọgbà sísìn*
*Ẹlẹ́íyẹ ò ní fẹ́ ò fò lọ*
*La fi bínú gbara wa lọ́wọ́ ẹni funfun*
*Ọpẹ́ ló yẹrú tá a jára wa gbà nínú ìgbèkùn*

Èròǹgbà àjùmọ̀ṣe nípa gbígba òmìnira, pàápàá pẹ̀lú akitiyan àwọn olóṣèlú bí Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀, Ahmadu Bello, Nnamdi Azikwe, àti Herbert Macauclay, gẹ́gẹ́ bí Ọládàpọ̀ ti ṣe dunnú; ni láti mójú tó àníyàn àti ẹ̀dùn ọkàn àwọn ọmọ Nàìjíríà nípa ìṣèlú àti ètò ọrọ̀-ajé. Èrò akéwì ni pé, lẹ́yìn bíbọ́ lóko amúnisìn àwọn ìjọba ilẹ̀ Gẹ̀ẹ́sì, ètò ìṣèlú Nàìjíríà yẹ kó pèsè ohun amáyédẹrùn fún gbogbo ọmọ orílẹ̀-èdè yìí tó kópa nínú

akitiyan ìjìjàgbara fún ìgbòmìnira. Ohun tó fa àwíjàre akéwì ni pé òmìnira Nàìjíríà sún mọ́ àkókò tí orílẹ̀-èdè yìí ní ànító ọ̀rọ̀ àti àṣeyọrí kúrò lọ́wọ́ àwọn àtọ̀húnrìnwá tó jẹ gàba lé tẹrú-tọmọ lórí. Ṣùgbọ́n, ṣe ló dàbí ẹni pé Nàìjíríà bọ́ kúrò lọ́wọ́ amúnisìn kan bọ́ sí ọwọ́ *amúnisìn* mìíràn (àwọn olóṣèlú). Tí òmìnira wá di *omi ìnira* fún tọmọdé tàgbà tó fọkàn sí bíbọ́ kúrò nínú ìgbèkùn aláwọ̀ funfun. Nípa lílo àfiwé ẹlẹlọ̀ọ́, *olówó-ẹrú*, *olówó-ìwọ̀fà* àti *ẹlẹ́íyẹ*, akéwì ṣe àlàfibọ̀ ìkìlọ̀ sí ìdùnnú rẹ̀ pé kì í ṣe dídùn inú ìjọba amúnisìn ni pé kí Nàìjíríà di orílẹ̀-èdè olómìnira.

Àǹfààní ló yẹ kí àjọ̀dún òmìnira tó máa ń wáyé ní ọjọ́ kìíní, oṣù kẹwàá lọ́dọọdún ní Nàìjíríà jẹ́ fún ìjọba àpapọ̀, ìpínlẹ̀, àti ti ìbílẹ̀ jẹ́ láti máa ṣe ìṣirò *iṣẹ́ ìríjú* wọn lórí àléèfà. Ọ̀pádọ̀tun (1976:16) ṣe àgbéyẹ̀wò ọ̀kan nínú irú àjọyọ̀ bẹ́ẹ̀ nínú *Àríyá Ọdún Kẹtàlá T'áa ti Gbòmìnira* nínú èrò àjọyọ̀ rẹ̀ pé:

*Orílẹ̀-èdè yìí, ẹ kú àjọ̀dún òmìnira,*
*Ẹ kọrin ijó s'Olúwa, Nàìjíríà ẹ fò fáyọ̀,*
*Àṣé bójú bá rí 'bi tí kò fọ,*
*Ayọ̀ ńlá ní ó pẹ̀kun rẹ̀.*
*Ògbòdìyàn Nàìjíríà d'ọ̀rọ̀ ìtàn,*
*Afẹ́fẹ fẹ́ fẹ́ bíi k'ígi oko ó wó*
*Ìjí sì jà jà bíi kí 'tàkùn ó fàtu,*
*Oníkálukú ló ń retí eji, ...*

Àyọlò òkè yìí tọ́ka sí kò-pé-kò-jìnnà ti ogun abẹ́lé Nàìjíríà tó wáyé láàrin ọdún 1967 sí 1970 parí. Èrò akéwì tó mú kó pè fún ìdúpẹ́ kò ṣẹ̀yìn ogún abẹ́lé (ogun Ojukwu) tó fẹ́rẹ̀ pín Nàìjíríà sí yẹ́lẹyẹ̀lẹ nígbà náà. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Ọ̀gágun Yakubu Gowon ló wa lórí àléèfà nígbà náà, ìṣèlú tí àwọn ẹ̀yà Igbo lérò pé ó ṣapá kan jànmọ́; èyí ló ṣokùnfa èròǹgbà àwọn ara gúsù ìlà

oòrùn Nàìjíríà láti *ya* kúrò lára Nàìjíríà. Ìṣẹ̀lẹ̀ mánigbàgbé yìí ló bí òwe Yorùbá pé, *Ó le kú, ìjà Ọ̀rẹ̀*. Ọgbẹ́ ọkàn to jẹ́ àtubọ̀tán ogun náà jẹ́ ìkùnsínú ẹlẹ́yàmẹ̀yà lọ́kàn ọ̀pọ̀lọpọ̀ tó pàdánù ẹbí àti dúkìá wọn lásìkò ogun abẹ́lé, pàápàá àwọn ẹ̀yà Igbo títí dòní. Yàtọ̀ sí pé ogún parí, akéwì tún wo sàkun àwọn ìrírí àsìkò ìdẹ̀ra tó pọwọ́ lé e. Lára àwọn ohun tí a lè kà sí àṣeyọrí ìjọba ológun ìgbà náà tí akéwì wòye rẹ̀ ni: ẹ̀kúnwó oṣù àwọn òṣìṣẹ́ (Owó Udoji); sísọ Nàìjíríà di ìpínlẹ̀ méjìlá; ètò ọrọ̀-ajé tó dúróore àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ (Kọ́láwọlé, 1988:135). Nínú ayẹyẹ ìrántí ìgoróyè, gẹ́gẹ́ bí ti àjọ̀dún òmìnira, ohun ìwúrí ni kí Ọba aládé Yorùbá, àwọn ìjòyè àti àwọn ará ìlú rí ohun mèrèmère tọ́ka sí. Ìdí ni pé, Ọba tó jẹ tó fiyùn lọ́lẹ̀, ọmọ aráyé kò ní gbàgbé, èyí tó sì jẹ tí ìlú di ìgbòrò; ọmọ aráyé kò ní gbàgbé bákan náà. Orin yìí fi ìdí èrò àti ìgbàgbọ́ Yorùbá nípa ojúṣe olórí nínú ìṣèlú múlẹ̀:

*Láyé Olúgbọ́n, a dá ‘borùn méje*
*Ẹ ò máa fi ‘wé lórin*
*Láyé Arẹ̀sà, a dá ‘borùn mẹ́fà*
*Ẹ ò máa fi ‘wé lórin*
*Láyé Oníkòyí, a ra kókò, a rà àrán,*
*A ra sányán baba aṣọ, à f’ọ̀lẹ*
*Ẹní pé ‘lẹ̀ yìí o dùn, ko ya kẹ́rù sọ́kọ ò*
*Ayé ilé, à f’ọ̀lẹ*
*Ló le pé’lẹ̀ yìí o dùn,*
*Ko ya kẹ́rù sọ́kọ, kó gboko lọ.*

Irúfẹ́ orin yìí, nínú àṣà Yorùbá tọ́ka sí ipa mánigbàgbé tí àwọn Ọba pàtàkì mẹ́tẹ̀ẹ̀ta ọjọ́un àná kó nínú ètò ìṣèlú ìlú ẹnìkọ̀ọ̀kan wọn pẹ̀lú àmúlò ọgbọ́n àti ìmọ̀ abínibí Yorùbá lọ́nà tí ayé fi gbẹdẹmukẹ fún àwọn ará ìlú wọn. Ìlànà ètò ìṣèlú ìgbà náà jẹ́ kí wọ́n ní ètò ọrọ̀-ajé tó fẹsẹ̀ rinlẹ̀; ìṣèlú tó dúróore; ààbò

tó péye; ìṣẹ̀tọ́ fún tẹrú-tọmọ àti ìdàgbàsókè tó múnádóko. Àkíyèsí wà pé, irú àfojúsùn, ẹ̀mí ìfọkànsìn àti àṣeyọrí Olúgbọ́n, Arẹ̀sà àti Oníkòyí kò fi bẹ́ẹ̀ wọ́pọ̀ lóde-òní nínú ìṣèlú mọ́. Ìdí ni pé, '*ọ̀làjú'* ń ṣe *ìtàpórógan* pẹ̀lú àṣà ìbílẹ̀, ìmọ̀ abínibí Yorùbá àti ìjọba tiwa-n-tiwa, èyí sì ń ṣe àkóbá ńláǹlà fún ìmúdúró-ṣọ̀kan Nàìjìríà. Ọládàpọ̀ wo ìpilẹ̀ bí Nàìjíríà ṣe di orílẹ̀-èdè olómìnira nígbà tí Ọ̀pádọ̀tun ṣe ìgbéléwọ̀n ibi tí nǹkan dé dúró lẹ́yìn ọdún kẹtàlá gẹ́gẹ́ bí a ti rí i nínú ewì wọn. Ọ̀kan lára ohun tí a ṣàkíyèsí nípa àpẹẹrẹ àfijọ nínú ìṣèjọba tiwa-n-tiwa àti ti ìṣèlú Yorùbá ni pé gbogbo ènìyàn ló máa ń pète fún òmìnira kúrò lọ́wọ́ *ìmúnisìn/ìjẹgàbalé*; ṣùgbọ́n ṣàṣà ènìyàn ló máa ń ṣetán láti ṣe *ìrúbọ* ìfira-ẹni-jìn fún gbígba òmìnira tàbí ìdàgbàsókè rẹ̀.

Ọ̀nà kan pàtó tí a lè gbà ní ìmúdúró ètò ìṣèlú tó ta gbòǹgbò dúró lórí sísọ àti ṣíṣe bí ó ṣe yẹ kí nǹkan rí. Kì í ṣe ọ̀nà yìí nìkan ni àwọn akéwì àpilẹ̀kọ Yorùbá gbà gbé ewì wọn kalẹ̀. Wọ́n tún sọ̀rọ̀ lórí àwọn àmúyẹ tó rọ̀ mọ́ ìmọ̀ abínibí àti ipa tí yóò ní bí ìjọba bá lè mú wọn lò nínú ètò ìṣèlú ẹlẹ́ga mẹ́ta (ìjọba àpapọ̀, ìjọba ìpínlẹ̀, àti ìjọba ìbiílẹ̀) Nàìjíríà. Àkíyèsí wọn lórí ìṣèlú orílẹ̀-èdè yìí fi hàn pé wọ́n mọ ewu tó rọ̀ mọ́ fífi ọwọ́ dẹngbẹrẹ mú ọ̀rọ̀ ìṣèlú, pàápàá láwùjọ ọ̀làjú tí ẹnìkọ̀ọ̀kan, ìlú, àti ẹ̀yà kọ̀ọ̀kan ti mọ ẹ̀tọ́ wọn. Àkíyèsí jẹ́ àbùdá àkọ́kọ́ pàtàkí tí a lè sọ pé ó ṣe kókó jùlọ fún orílẹ̀-èdè ọlọ́pọ̀ ẹ̀yà bí i ti Nàìjíríà tó ṣẹ̀ṣẹ̀ ń dìde láti fẹsẹ̀ múlẹ̀ nípa ètò ìṣèlú àti ọrọ̀-ajé. Adéwọlé (1987:56) nínú ewì rẹ̀, *Àkíyèsí* wòye pé:

*Àkíyèsí kéré,*
*Ṣùgbọ́n bó ti kéré tó, l'ó búrú tó*
*Ẹni t'ó f'ojú kékeré w'àkíyèsí*
*Olúwarẹ̀ ó k'àbùkù*
*Ẹni tí kò l'ákìíyèsí , k'ò leè ṣ'ohunkohun t'ó dára*

*Àkíyèsí ṣe pàtàkì n'ígbèé ayé ẹ̀dá èèyàn*
. . .
*Ẹni tó l'ákìíyèsí l'ó leè lo 'lé ayé pẹ́,*
*Ènìyàn t'ó l'ákíyèsí l'àá pè l'ágbà*
*B'ágbà kò bá l'ákìyèsi, kò ní pẹ́ kú,*
*Ó yẹ k'ẹ́ni t'ó jẹ́ baba ó ní'fura*
*Nítorí ìfura l'oògùn àgbà*

Nínú àyọlò yìí, Adéwọlé (1987) fi yé wa pé àkíyèsí ni olórí ohun gbogbo nípa ohun tí ènìyàn bá ń ṣe, yálà lórí nǹkan tó ti ṣẹlẹ̀ sẹ́yìn; èyí tó ń ṣẹlẹ̀ lọ́wọ́lọ́wọ́ tàbí tó ṣeé ṣe kó ṣẹlẹ̀ lọ́jọ́ iwájú. "Ìfura loògùn àgbà", gẹ́gẹ́ bí akéwì ṣe wí. Ìkìlọ̀ lórí ewu tó rọ̀ mọ́ fífi ojú kò-tó-nǹkan wo àwọn oríṣiríṣi ìṣẹ̀lẹ̀ tó pè fún àtúnṣe, pàápàá ní Nàìjíríà tí gbogbo àgbáyé ń wò bí aṣíwájú ẹ̀yà Adúláwọ̀ wà nínú ìdúróẁoye akéwì yìí. Yorùbá bọ̀, wọ́n ní Bọ́mọdé bá ṣubú, a wo iwájú; bágbà bá ṣubú a wẹ̀yìn wò. Ọládàpọ̀ tọ́ka sí ìpìlẹ̀ òmìnira Nàìjíríà; Ọ̀pádọ̀tun bojúwẹ̀yìn láti fi ojú-inú wo ibi tí nǹkan dé dúró lẹ́yìn ọdún kẹtàlá. Ìṣẹ̀lẹ̀ wọ̀nyí pè fún àkíyèsí gẹ́gẹ́ bí ìwòye Adéwọlé nípa pàtàkì níní àkíyèsí. Àbùdá ìmọ̀ abínibí Yorùbá farahàn nínú àgbékalẹ̀ àti àrògún àwọn akéwì mẹ́tẹ̀ẹ̀ta. Nípa àkíyèsí ni ẹnìkọ̀ọ̀kan, ìlú tàbí orílẹ̀-èdè fi lè máa ṣe ìgbéléwọ̀n láti ìgbà dé ìgbà láti mọ àwọn àṣeyọrí tàbí àwọn nǹkan tó pè fún àtúnṣe nípa ètò ìṣèlú àti ọrọ̀-ajé. Bí olórí kò bá ni àkíyèsí, tí ìlú yóò fi túká mọ́ ọn lórí kò ní mọ̀! Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé akéwì kò mẹ́nu ba ọ̀rọ̀ ìṣèlú, síbẹ̀, ṣàṣà ni ẹni tí kò mọ rírì fífi iyè sí bí ètò ìṣèlú ṣe ń lọ láwùjọ, bí àwọn adarí kò bá tilẹ̀ bìkítà. Àkíyèsí àwọn ènìyàn lórí bí nǹkan ṣe ń lọ tó jẹ́ àbùdá káríayé farahàn nínú bí àwọn ènìyàn ṣe máa ń tẹ́tí léko fún ìròyìn lórí rédíò/tẹlifíṣàn àti ìwé ìròyìn kíkà. A tilẹ̀ lè sọ pè àìníàkíyèsí ló ṣokùnfà oríṣiríṣi *ìṣòro kéékèèkéé* tó búrẹ́kẹ ní

Nàìjíríà lónìí. Àìkíyèsára a máa mú ìfàsẹ́yìn bá orílẹ̀-èdè. Ìdí nìyí tí Adélékè (2010:6) nínú *Nàìjíríà Dòrí* fi pe àkíyèsí àwùjọ sí ohun tó wòye gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan lára ojúlówó ìpìlẹ̀ ìṣòro ajẹmọ́-ìṣèlú/ọrọ̀-ajé Nàìjíríà:

*Ṣé irè oko lohun àmúṣọrọ̀ nípìlẹ̀*
*Ṣe bígi oko ló ń fajé wọlé*
*Ọ̀pẹ pọ̀ lọ jàǹtìrẹrẹ, ẹ̀pà pọ̀ lọ jàra*
*Kòkó kò ṣe é kó tán lóko*
*Bẹ́ẹ̀ lòbítíbitì gẹdú ń bẹ níjù*
*Tẹrú tọmọ ló gbájú mọ́ṣẹ́ oko*
*Bọ́dún bá yípo lásìkò ìkórè*
*Àlùpa loúnjẹ ọ̀hún lọ́jà*

Àkọlé ewì yìí, *Nàìjíríà Dòrí,* tó jẹ́ àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́, fún wa ní òye ipò *ìdíbàjẹ́/akúrẹtẹ̀*, gẹ́gẹ́ bí òrí inú oòrùn, tí Nàìjíríà wà lónìí. Bí yóò *yọ* tán, tàbí àmúpadà-bọ̀-sípò yóò dé bá a ni ìbéèrè tí kò dájú pé ẹnìkan lè fọwọ́ sọ̀yà dáhùn. Ẹ̀rí pé *Nàìjíríà Dòrí* farahàn nínú ìṣèlú, ọrọ̀-ajé, àìríṣẹ́ṣe àwọn àkẹ́kọ̀ọ́gboyè/oníṣẹ́-ọwọ́, iyelórí Náírà tó dakúrẹtẹ̀, ọ̀wọ́n gógó oúnjẹ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Èrò Yorùbá tó sọ wí pé, bí oúnjẹ bá kúrò nínú ìṣẹ́, ìṣẹ́ bùṣe ni akéwì gbé jáde nínú àyọlò yìí. Gẹ́gẹ́ bí àkíyèsí akéwì, iṣẹ́ abínibí, àgbẹ̀, tó jẹ́ iṣẹ́ ìpìlẹ̀ Yorùbá àti àwọn ẹ̀yà yòókù ni ìṣèlú àti ọrọ̀-ajé Nàìjíríà dúró lé lẹ́yìn òmìnira, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé wọ́n ti ṣe àwárí epo rọ̀bì ní Oloibiri ní ìpínlẹ̀ Bayelsa láti ọdún 1958. Títẹramọ́ iṣẹ́ àgbẹ̀ jẹ́ àsìkò ìgbé ayé ìdẹra nínú ètò ìṣèlú Nàìjíríà nígbà náà. Kò sí ẹ̀yà kan ní orílẹ̀-èdè yìí tí kò ní ìmọ̀ kíkún nípa iṣẹ́ àgbẹ̀ àti pàtàkì rẹ̀ fún àtijẹ-àtimu àti fún ìdàgbàsókè ọrọ̀-ajé. Ètò ọ̀gbìn, owó-orí sísan àti owó-orí ọjà àkọ́lọ-sí-orílẹ̀-èdè mìíràn nìkan ní ọ̀nà tí owó fi ń wọlé sí àpò ìjọba lẹ́yìn òmìnira (Bámishayé, 1976:76).

Ẹ̀yà Yorùbá ló ni kòkó, Hausa ló ni ẹ̀pà, nígbà tí àwọn Igbo jẹ́ ọlọ́gbìn gẹdú, epo pupa àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bákan náà, àwọn ẹ̀yà yòókù kò gbẹ́yìn nínú iṣẹ́ àgbẹ̀ ṣíṣe. Lẹ́yìn àjẹyó àti àjẹṣẹ́kù, gẹ́gẹ́ bí akéwì ti ṣàlàyé, orílẹ̀-èdè yìí tún máa ń ta irè oko sí ilẹ̀ òkèèrè. Èyí fi hàn pé, a kò le sọ̀rọ̀ nípa ìmúdúró ètò ìṣèlú orílẹ̀-èdè kan, ká sọ wí pé, kí ètò ọrọ̀-ajé gbẹ́yìn. Àwọn akéwì tí a lo ewì wọn mọ̀ wí pé ọdún bí i mélòó kan lẹ́yìn òmìnira jẹ́ ìgbà ìrọ̀rùn nínú ìṣèlú, ọrọ̀-ajé àti ohun amúlùúdùn Nàìjíríà nítorí pé, wọ́n mọ̀ ìpìlẹ̀ ọ̀rọ̀ nípa ìṣèlú Nàìjíríà. Ìdí nìyí tí akéwì fi sọ àsọyé ọ̀rọ̀ pé Nàìjíríà ti di *òrí* tó ń yọ́ nítorí àwọn ẹ̀rí àfojúrí fi hàn pé nǹkan kò lọ déédéé mọ nínú ètò ìṣèlú àti ọrọ̀-ajé. Ipò Nàìjíríà tí Adélékè ṣe àpèjúwe yìí ló mú kí Ṣàngótóyè (2010:118) nínú *Ètùtù Ìṣọ̀kan*, káàánú pé:

*Àánú orílẹ̀-èdè yìí ṣe mí*
*Torí rẹ̀ ni mo ṣe ń da omi lójú*
*Bí i tegbére lọ́jọ́ gbogbo*
*Òní ọ̀tẹ̀, ọ̀la wàhálà ló ń pa mí lẹ́kún*
*Rúdurùdu táyé ṣe ń lọ ló ń pa mí nígbe*
*Ibi tọ́kọ̀ orílẹ̀-èdè yìí ń lọ kò yé wa mọ́*
*Ibi à ń rè, a kò tilẹ̀ mọ̀*

Kí ló fa ìkáànú akéwì fùn Nàìjíríà bí kò ṣe ewu tó lè súyọ nítorí gbígbàgbé *ìpìlẹ̀* tí Ọládàpọ̀, Ọ̀pádọ̀tun àti Adélékè mẹ́nu bà, èyí tó ṣokùnfà ọ̀tẹ̀, wàhálà àti rúdurùdu. Yorùbá ti parí ọ̀rọ̀ pé, "odò tó gbàgbé orísun rẹ̀, dandan ni kó gbẹ". Nínú ohun tó ṣeé ṣe kó fa *ẹkún àsunùndá* akéwì ni bí, "oní ẹjọ́", "ọ̀la àròyé" kò ṣe ní di adínàgboòkú ìmúdúró-ṣọ̀kan Nàìjíríà. Akéwì gbarata nítorí pé ó dà bí ẹni pé, lọ́wọ́lọ́wọ́, ìṣèlú Nàìjíríà àti gbogbo ohun tó rọ̀ mọ́ ọn kò ní ìlànà kan gbòógì tí ó ń tẹ̀lé. Ìdí nìyí tí

Ṣàngótóyè (2010) fi wòye pé ibi tí 'ọkọ̀' orílẹ̀-èdè yìí ń lọ, kò sí ẹni tó yé. Bẹ́ẹ̀, iwájú ló yẹ kí ọ̀pá ẹ̀bìtì "ọkọ" Nàìjíríà máa ré sí, bí a bá wo irúfẹ́ ìlàkàkà àti àṣeyọrí àwọn olùfọkànsìn olóṣèlú tí wọ́n ti ṣèlú, pàápàá ní ẹkùn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta àná - Ẹkùn Àríwá (Northern Region), Ẹkùn Ìwọ̀-Oòrùn (Western Region) àti Ẹkùn Ìlà-Oòrùn (Eastern Region) sẹ́yìn àti ohun àlùmọ́nì tó pọ̀ yannturu ní Nàìjíríà. Gẹ́gẹ́ bí òwe Yorùbá, Bọ́mọdé bá ń gégi nígbó, àgbà ní ó mọ ibi tó máa wó sí. Àtàrí Àjànàkú (2011:13), ìnagijẹ akéwì kan, nínú *Níbo là ń rè?* nàá wòye pé iná ti jó dórí kókó nípa ìṣèlú Nàìjíríà, ó ké gbàjarè pé:

*Níbo layé dorí kọ?*
*Ìyà yìí pọ̀ o èè, èyí mà le ooo*
*Àwọn akọni ilẹ̀ yìí wa dà?*
*Níbo ni wọ́n fojú pamọ́ sí?*
*Ṣé wọ́n ti kọni sílẹ̀ ni?*
*Ṣé wọn ò le kọ̀yà fúnni ni ?*
*Ilé ìyà ló mà kù tí wọ́n mà ń kọ́ fún wa oo*
*Wọ́n ń kó wa tà bí ẹrú*
*Wọ́n ń kó wa tà bí ẹran ìso*
*Kò sákọni nílẹ̀ yìí mọ o ee*
*Ọmọ́rèmí ti lọ tían rére*
*Ifájuyì ti ràjò àrèmabọ̀ o*
*Àwọn akọ̀nìyànsílẹ̀ ló màmà kùù*

Kókó méjì tí Àtàrí Àjànàkú tọ́ka sí ni ìpọ́njú àwọn mẹ̀kúnnù nínú ètò ìṣèlú Nàìjíríà, níbi tí "olóṣèlú" ti ń rẹ́ ará ìlú jẹ. Àwọn ìbéèrè pèsìjẹ tí akéwì béèrè jẹ́ kí á mọ̀ pé gbogbo nǹkan kò fararọ bí i ti àtẹ̀yìnwá nínú ètò ìṣèlú Nàìjíríà. Bẹ́ẹ̀ sì ni sílébù "yà" àti "kọ̀" tí akéwì fi dárà jẹ àpẹẹrẹ ìyapa tó jẹyọ nínú ìṣèlú ìgbàlódé tó tako ìlànà ìjọba tiwa-n-tiwa- *tó jẹ́ ìjọba ará ilú, láti ọwọ́ ará ilú fuń ará ìlú* (Payne & Nassar, 2006: 205 - 206).

Bákan náà, akéwì mẹ́nu ba àwọn àwòkọ́ṣe aṣaájú rere tí wọ́n ti rèwàlẹ̀ àṣà lẹ́yìn fífi ìwà akíkanjú àti ọmọlúàbí sin ìlú/orílẹ̀-èdè dé ojú ikú. Mọrèmi, akọni-bìnrin, ni ìtàn fi yé wa pé ó fi ara rẹ̀ sílẹ̀ fún ogun Igbo fún ìkólẹ́rú. Lẹ́yìn-ò-rẹyìn ó gba Ilé-Ifẹ̀ kúrò lọ́wọ́ àṣírí àti ẹ̀tàn àwọn Igbo. Ifájuyì, jagunjagun, náà fi ẹ̀mí rẹ̀ lélẹ̀ fun Ọ̀gágun Aguyi Ironsi (ọ̀gá rẹ̀, tó jẹ́ olórí ológun Nàìjíríà) tó ṣàbẹ̀wò sí i ní Ìbàdàn ní ọdún 1967 tí ìdìtẹ̀-gbàjọba wáyé.

Lóòótọ́, ọjọ́ pẹ́ tí òwò ẹrú ti kásẹ̀ nílẹ̀, akéwì fi ìgbé ayé àwọn ọmọ Nàìjíríà wé ti *ẹrú* nítorí ìrírí ìnira wọn. Yorùbá bọ̀, wọ́n ní, àìsunwọ̀n ará ayé níí mú ni rántí ará ọ̀run. Èyí ló fa ìpè akéwì, nípa rírawọ́ ẹ̀bẹ̀ sí àwọn àgbààgbà, àti àwọn "ọlọ́gbọ́n ẹ̀dá" láti fi ikùn lu ikùn láti wá ọ̀nà àbáyọ sí ìṣòro Nàìjíríà. Bí ọ̀rọ̀ ìṣèlú bá ń dòbírípo ní ilẹ̀ Yorùbá, àwọn àgbààgbà máa ń pé bíríkótó láti ṣe àtúnṣe. Ẹ̀dùn ọkàn akéwì ni pé púpọ̀ nínú àwọn olóṣèlú tí àwùjọ fọkàn tẹ̀ bí i "olùkọ̀yà" ni wọn kò ṣetán láti ṣe ojúṣe wọn, pàápàá fún àwọn mẹ̀kúnnù tí àwọn akéwì ń gbẹnusọ fún. Adélékè pè fún àmúlò ìmọ̀ abínibí nínú iṣẹ́ àgbẹ̀, láti kìlọ̀ ìyàn tó ń rúgbó bọ̀. Níwòye Ṣàngótóyè, ọ̀rọ̀ ìṣèlú Nàìjíríà kò yé tolórí tẹlẹ́mù mọ́. Ṣùgbọ́n Àjànàkú sọ yanya pé, *ọ̀gbun àìnísàlẹ̀* ni *ọkọ̀* ìṣèlú orílẹ̀-èdè yìí ń rè bí àwọn àgbààgbà ọ̀mọ̀ràn kò bá dá sọ́rọ̀ náà tàbí bí àwọn adarí bá kọ ìmọ̀ràn àwọn akéwì. Láti mú kí àtúnṣe wáyé, àwọn akéwì àpilẹ̀kọ Yorùbá gbé ìmọ̀ràn lóríṣiríṣi kalẹ̀.

## Ìmọ̀ràn Àwọn Akéwì Fún Ìmúdúró-ṣọ̀kan àti Ìdàgbàsókè Nàìjíríà

Lẹ́yìn tí a tí rí ọ̀kan-ò-jọ̀kan àléébù tó súyọ nínú ètò ìṣèlú Nàìjíríà, ó ṣe pàtàkì kí á wo oríṣiríṣi ìmọ̀ràn tí àwọn akéwì gbé kalẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà àbáyọ sí ìṣòro ìṣèlú Nàìjíría. Nínú *Ìṣọ̀kan*, Adétúnjí (1989:67) polówó ìfọwọ́sowọ́pọ̀:

*Nǹkan tí a bá dìjọ wò régérégé níí gún*
*Ohun tí ìsín bá dáwò, kì í pọ́jọ́*
*Èyí tí ìkòrò bá nìkan wò kì í pọ́ṣù*
*Hausa ni ọ́ ni àbí Kàlàbarí?*
*Yoòbá ni ọ́ ni àbí Yíbò?*
*Kó dà bó o jẹ́ Sẹ̀kírì, bó o jẹ́ Fúlàní*
*Odò Ọya èyí ti so wá pọ̀ ná o!*
*Lọ́lá Olúwa, Ọ̀yà ò níí yà wá ní túláàsì*
*Àjèjé ọwọ́ kan ò gbẹ́rù dórí*
*Àgbájọ ọwọ́ ló ṣe é sọ̀yà*
*Ẹ jẹ́ ká parapọ̀, ká ṣiṣẹ́ ìlú*
*Ẹ jẹ́ ká fara mọ́ra, ẹnìkan ò leè da ṣe*
*Ẹ jẹ́ ká sowọ́pọ̀, kórílẹ̀-èdè yìí ó lè gòkè*
*Ìṣèlú ẹlẹ́yàmẹ̀yà yìí ò le gbé wa dé 'bì kankan*
*Ká fìfẹ́ gbé pọ̀ ló lè fún wa nírọ̀rùn*

Nínú ètò ìṣèlú Nàìjíríà, pàápàá lẹ́yìn òmìnira, kò sí ìfòyà fún ẹnìkọ̀ọ̀kan - tonílé tàlejò láti rìn fàlàlà níbikíbi. Ìwà abínibí ẹ̀yà kọ̀ọ̀kan nípa ìbágbépọ̀ ẹ̀dá ni kálukú gbé wọ̀ bí *ẹ̀wù* nígbà náà. Èyí fàáyè gba rírí ara wọn bí *ọmọ ìyá kannáà*. Akéwì pè fún ìṣọ̀kan pẹ̀lú ìtẹnumọ́ pé, *àjèjé ọwọ́ kan kò gbẹ́rù dórí*. Adétúnjí rí àgbáríjọpọ̀ oríṣiríṣi ẹ̀yà tó di Nàìjíríà gẹ́gẹ́ bí àǹfààní tó lérè. Ṣé, ká rìn ká pọ̀, yíyẹ níí yẹni. Pẹ̀lú ojú ìmọ̀ àṣà Yorùbá àti èrò rẹ̀ lórí ohun àmúṣà-lóògun, akéwì wo sàkun adùn kí ẹ̀yà kan rí ẹ̀yà kejì bí ọmọ ìyá kan ṣoṣo tí *okùn ìfẹ́* orílẹ̀-èdè

olómìninra so papọ̀. Èrò Ṣàngótóyè (2010:119) nínú *Ètùtù Ìṣọ̀kan* fi hàn pé ìforíkorí jẹ́ dandan :

*Ká ronú gidi lórí ohun a lè ṣe*
*Tá ó fi fòpin sí wàhálà lónìí, ìjàngbọ̀n lọ́la*
*Tórílẹ̀-èdè yìí yóò ṣe tòrò tí yóò ṣe rójú*
*Táyé ó fi tu tẹrútọmọ lára*
*Èmi ì bá dámọ̀ràn ìpàdé ńlá*
*Níbi a ó pe ọ̀pọ̀ èniyàn fún ìjíròrò*
*Ká polórí, ká pẹlẹ́mù orílẹ̀-èdè yìí*
*Ká pe bọ̀rọ̀kìnní ìlú síbi àpérò, ká parúgbó*
*Ká sì pomidan, ká polórí ẹlẹ́sìn gbogbo pẹ̀lú*
*Ká pe Ọba alayé gbogbo, kọ́mọ ilé-ìwé ó láṣojú*
*Káwọn òṣìṣẹ́ ọba ó má sì gbẹ́yìn,*
*Kí ikọ̀ ó wá láti inú ẹ̀yà gbogbo*

. . .

*Kí wọn ó sọ̀rọ̀ lórí kí ló ń fa wàhálà,*
*Kí wọn ó sì mú àbá wá lẹ́yìn ìjíròrò*
*Bí ká ṣì wà papọ̀ ló le mú ìrẹ́pọ̀ wá, a jẹ́ pé ká tún jọ máa ṣe*
*Kí wọn ó wá ronú ọ̀nà àti dín ìrẹ́jẹ àwọn ẹ̀yà kan kù*

Akéwì gbé ìmọ̀ràn kalẹ̀ lórí ohun tó lérò bí ọ̀nà àbáyọ sí ìṣòro ìṣèlú Nàìjíríà. Ṣàngótóyè rí Nàìjíríà gẹ́gẹ́ bí "ogún àjọni", èyí tó mú kó wòye pé, "ìbí kò ju ìbí, bẹ́ẹ̀ ni kò sẹ́rú, kò sọ́mọ." Ọgbọọgba ló yẹ kí pípín àǹfààní tó bá rogún nínú ọrọ̀-ajé sí àsùnwọ̀n ìjọba ó jẹ́ láìfi ẹ̀tọ́ ẹ̀yà kankan tó parapọ̀ di orílẹ̀-èdè Nàìjíríà dùn wọ́n. Bákan náà, akéwì pè fún ìpàdé àpérò tó jẹ́ gbogbogbòò nínú èyí tí olóríjorí/ẹlẹ́gbẹ́jẹgbẹ́ yóò ti kó ipa tó jọjú láti wá ojútùú sí àwọn làásìgbò tó ń pako dínà ìtẹ̀síwájú ètò ìṣèlú orílẹ̀-èdè yìí. Ṣé, ọmọdé gbọ́n àgbà gbọ́n la fi da ilẹ̀ Ifẹ̀.

Ìmọ̀ràn akéwì fi ìdí ọ̀rọ̀ Yorùbá múlẹ̀ pé, ẹnu ríran ju ojú lọ, tàbí ká sọ pé, nínú ìmísí, gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ Ìṣọ̀lá (2012 :3) ni Ṣàngótóyè (2010:119) ti sọ̀rọ̀. Ewì Ṣàngótóyè àti àwọn ewì mìíràn di títẹ̀ jáde ní ọdún 2005, àpérò fún ìmúdúró-ṣọ̀kan Nàìjíríà tí akéwì pè fún wáyé ní ọdún 2014. Ohun tí a kò le sọ ní pé, bóyá àpérò náà kógojá nípa mímẹ́nuba àwọn ojúlówó ìṣòro Nàìjíríà. Lọ́nà mìíràn ẹ̀wẹ̀, ǹjẹ́ àbọ̀ iṣẹ́ ìríjú àwọn aṣojú tó kópa nínú àpérò nàá yòó so èso rere nípa mímúlò fún ìjọba àpapọ̀ ; pàápàá lẹ́yìn tí ìjọba tó ṣe agbátẹrù ìpàdé àpérò náà ti kógbá wọlé. Bí ìpàdé àpérò bá so èso rere tán, ó ṣe pàtàkì kí ìrẹ́pọ̀ wà nípa gbígba àlàáfíà láàyè. Adéwọlé (1987:17), nínú *Àlàáfíà*, náà rí àlàáfíà gẹ́gẹ́ bí ohun tó lè dènà ìṣòro tó ń kojú ètò ìṣèlú Nàìjíríà, ó ní :

*Àlàáfíà un l'àa fií gbé 'lé tá a bá kọ́*
*Àlàáfíà un l'àá fií ṣ'iṣẹ́ tá a bá ń ṣe*
*B'álàáfíà kò bá sí, kò sóhun tó lè mú 'dùnnú wá*
*B'ó ti wù k'ílé ó dára tó, inú igbó níí jọ lójú ẹni*
*Àlàáfíà l'ó lè mọ́ọ̀dẹ̀ dùn yùngbà*
*B'álààfíà ò bá sí ìlú 'ò leè r'ójú*
*B'ílùú ò rójú, ìpínlẹ̀ ò leè dá t'órò*
*Orílẹ̀-èdè tí kò l'álàáfíà, kò leè pẹ́ẹ̀ túká*

Èrò akéwì wà ní ìbámu pẹ̀lú ìgbàgbọ́ Yorùbá pé, bọ́ọ̀dẹ̀ ò dùn bí ìgbẹ́ ni ìlú ń rí. Àgbékalẹ̀ akéwì bó ṣe to pàtàkì níní àlàáfíà láwùjọ ní ìpele ìpele jọ ìlànà ètò ìṣèlú Yorùbá, èyí tó farapẹ́ ti Nàìjíríà - ìlú (*Ọba/Ọlọ́jà*), ìlú kéréje (*Ọba*) àti abúlé (*Baálẹ̀*), agbo-ile (*Baálé*). Ìjọba àpapọ̀ (*Ààrẹ*), ìpínlẹ̀ (*Gómìnà*), ìjọba ìbílẹ̀ (*Alága*), Wọ́ọ̀dù (*Káńsélọ̀*). Bí abúlé ṣe kéré jọjọ tó nínú ìṣèlú Yorùbá, àlàáfíà rẹ̀ ní ipa tó ń kó, nítorí *ìrọ̀rùn eku ni ìrọ̀rùn ẹyẹ*. Ojúṣe Ọba àti àwọn ẹmẹ̀wà rẹ̀ ni láti dáàbò bò àwọn

ìlú àti abúlé àmọ̀nà rẹ̀. Èyí fi hàn pé, nínú ìṣèlú ẹlẹ́ga mẹ́ta Nàìjíríà -ìjọba ìbílẹ̀, ìjọba ìpínlẹ̀ àti ìjọba àpapọ̀, àlàáfíà ṣe kókó fún ìmúdúró àti ìdàgbàsókè Nàìjíríà. Yorùbá bọ̀, wọ́n ní, ilé la ti ń kó ọ̀ṣọ́ ròde. Bí *omi àlàáfíà* ilékilé bá dàrú yóò kan agbo-ilé, bẹ́ẹ̀ ni ìlú kò lè rọgbọ bí agbo-ilé méjì sí mẹ́ta bá ń dàrú. Bí ìlú kò bá rọgbọ yòó kan ìpínlẹ̀, ẹ̀wẹ̀, bí ìpínlẹ̀ bá ní ìpèníjà tó kọjá gèjíà, yóò di ìṣòro orílẹ̀-èdè.

Èyí túmọ̀ sí pé, oníkálukú ló ní ipa pàtàkì láti kó fún ìṣọ̀kan àti ìdàgbàsókè Nàìjíríà. Àkọlé ewì yìí gan-an, ètùtù ìṣọ̀kan jẹ́ àpẹẹrẹ ètò àtúnṣe kí ìlú lè tùbà tùṣẹ fún ìbágbépọ̀ tó dán mọ́nrán ní Nàìjíríà. Ìyàtọ̀ kan pàtàkì tó wà láàrin ìlànà ìṣèlú Yorùbá àti ti ìjọba tiwa-n-tiwa ni pé bí olórí ìlú ti lágbára tó, òfin akánilọ́wọ́kò (fífi ipá mú Ọba láti ṣí igba àìwò/ìwà/adémú) wà fún Ọba tó bá ṣe aṣemáṣe. Ní ìdàkejì ẹ̀wẹ̀, òfin a-ṣẹ̀-má-lù wà fún àwọn olóṣèlú lásìkò tí wọ́n bá wà lórí àléèfà. Ìdí nìyí tí Ẹlẹ́buìbọn, nínú, *Àwọn Òjẹ̀lú,* fi kan ojú abẹ níkòó pé:

*Ohun tó yẹ ká fi kọ́rọ̀ la ò fi kún wọn*
*A lọ́gbọ́n, a sì ní àṣà lọ́wọ́*
*Ohun abínibí wa kì í kùnà*

. . .

*Ẹ jẹ́ á fi wọ́n ré*
*Ẹ jẹ́ wọn ó búra fún wa*
*Kí wọn ó f'Ògún ṣaájú*
*Kí wọn ó gbórí ilẹ̀ ṣépè*
*Bóyá wọn a jẹ́ palákíbárú owó wa*
*Ká jẹ́ ilẹ̀ ó béèrè*

Ẹlẹ́buìbọn bu ẹnu àtẹ́ lù ọ̀kan lára ìwà ìbàjẹ́ tó jẹ́ àbùdá àwọn olóṣèlú kan, tí ẹ̀sìn ìbílẹ̀ Yorùbá takò, ìbúra èké. Akéwì gbà pé kàkà kí àwọn tí wọ́n pe ara wọn ní olóṣèlú ṣe ìlú ní

àǹfààní, ọ̀jẹ̀lú ni wọ́n dà. Àwíjàre yìí wà ní ìbámu pẹ̀lú èrò Àtàrí Àjànàkú tó gbà pé, kò sí *olùkọyá* mọ́, bí kò ṣe àwọn *amúnità* bí ẹrú. Èyí ló mú Ẹlẹ́buìbọn pè fún àmúlò ìmọ̀ abínibí tó farapẹ́ ìmùlẹ̀ tàbí ti ìdájọ́ ìlànà ìbílẹ̀ Yorùbá láti wagbò dẹ́kun fún ìwà jẹgúdújẹrá nínú ètò ìṣèlú Nàìjíríà. Láàrin àwọn Yorùbá, ìpìlẹ̀ ìdájọ́ òdodo dúró lórí ètò ìbára-ẹni-gbépọ̀ àti ẹ̀sìn. Fún ìdí èyí, àrúfin kan kì í lọ láìjìyà. Ipa takuntakun sì ni àwọn òrìṣà máa ń kó (Adégbindin 2012:176). Ifá fi ìdí èyí múlẹ̀ pé:

*Òfófó níí pẹrú*
*Èpè níí polè*
*Ilẹ̀ dídà ní í pọ̀rẹ́*
*Alájọbí ní í payèkan tó bá ṣebi*
- Abímbọ́lá (2006 :xvii)

Ìran Yorùbá kì í fẹ́ ṣe nǹkan èèwọ̀ tàbi èyí tó tako ẹ̀sìn ìbílẹ̀ wọn, nítorí ìtìjú àti àbùkù tó lè jẹ́ àtubọ̀tán rẹ̀. Ṣé, ìbàjẹ́ ọjọ́ kan, kò tán lógún ọdún. Ọmọ Yorùbá máa ń sá fún kí *orúkọ* wọn má bàjẹ́ tàbí kí wọ́n má rí ìjà ohun tó bá jẹ mọ́ àwọn ìbọ wọn, nitorí ọ̀wọ̀ tí wọ́n ní fún nǹkan méjèèjì wọ̀nyí. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé a kò le fi ìmọ̀ sáyẹ̀nsì ṣe ìwádìí àtubọ̀tán ìbúra èké, yóò ṣòro, gẹ́gẹ́ bí akéwì ti dábàá, kí ojúlówó ọmọ Yorùbá búra èké lójúbọ Òrìṣà. A gbìyànjú láti fi àwọn àwòràn méjèèjì yìí ṣe òdiwọ̀n ìjọra àti ìyàtọ̀ tó wà láàrin ìlànà ìṣèjọba àbáláyé Yorùbá àti ìjọba tiwa-n-tiwa Nàìjíríà.




Àtẹ 1: *Àwòrán Ìjọra àti Aṣèyàtọ̀ láàrin Ìṣèlú Yorùbá àti Ìjọba tiwa-n-tiwa*

## Ìlànà Ìṣèlú Abínibí Yorùbá pẹ̀lú Àfihàn Ètò àti Ojúṣe àwọn Olùdarí




Àtẹ 2: *Ìlànà ìṣèlú ìjọba tiwa-n-tiwa Nàìjíríà àti Ojúṣe àwọn Olùdarí*

**Akíyèsí:** Àwòrán yìí jẹ́ èrò àti àgbékalẹ̀ ẹni tó kọ àpilẹ̀kọ yìí.

Bí Yorùbá kò tilẹ̀ ní òfin àkọsílẹ̀ bí ti Nàìjíríà, tí kò sí àwọn akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ nípa òfin, wọ́n ní *òfin àkọ́sórí/àkọsọ́kàn*, tí ará ìlú ń ṣe àmúlò láti ìrandíran ní ìbámu pẹ̀lú ìmọ̀ àti àṣà abínibi wọn. Ìwà ọmọlúàbí ni olúborí atọ́nà fún ètò ìbágbépọ̀, ìṣèlú, ẹ̀sìn àti ìlànà ìhùwàsí Yorùbá (Fálétí, 2009). Òkédòkun (2003:28) nínú, *Nígbà tàwa,* ṣàlàyé pé:

*Agbádá ńlá ńlá la fi í mọba*
*Ìlẹ̀kẹ̀ jìnwìnnì ni tàwọn ìjòyè*
*Aṣọ ńlá ìwà àtàtà*
*Ni ti bọ̀rọ̀kìnní ìlú*
*Ẹni tí a bá pè lórí kò jẹ́ hùwà ibi*
*Ayé dáa gbáà nígbà tàwa*
*Ayé ló burú ni sùnmọ̀mí wọ̀lú dé*
*A ò mọ̀dágìrì nígbà tàwa*

Ìrírí àtẹ̀yìnwá àwọn olùdìbò nípa àwọn olóṣèlú jẹ́ ìpèníjà láti máa ṣe àwòfin ìhùwàsí àti ohun àrítọ́kasí tí olùdíje ti ṣe fún ará ìlú, kí wọ́n tó pinnú láti dìbò fún ẹnikẹ́ni tàbí ẹgbẹ́ òṣèlú kan. Àkọlé ewì akéwì, *Nígbà tàwa,* tọ́ka sí oríṣiríṣi ọ̀nà tí Yorùbá ń gbà ṣe àmúlò ìmọ̀ abínibí fún ìmúdúró ìṣèlú. Lóòótọ́, ipò Ọba àti ìjòyè jẹ́ ipò ọlá ṣùgbọ́n ojúṣe wọn nínú ká sin ìlú kò kéré. Òkédòkun (2003) mẹ́nu ba àwọn àbùdá ìdánimọ̀ bí: *adé, ìlẹ̀kẹ̀ jìnwìnnìn, aṣọ ńlá,* èyí tí kò jámọ́ nǹkankan bí *ìwà ọmọlúàbí* bá nu olórí. Kí Yorùbá tó fi ènìyàn joyè láàrin ìlú, ó ní láti jẹ́ ẹni rere nítorí náà, aṣọ ńlá kọ́ lèèyàn ńlá. Ìdí nìyí tí akéwì fi tẹnumọ́ ìwà rere gẹ́gẹ́ bí ìpìlẹ̀ rere fún ẹni tó fẹ́ fi orúkọ rere lọ́lẹ̀ de ọmọ. Lérò akéwì, èyí jẹ́ àbùdá àmúyẹ pàtàkì tí olórí ìlú/olórí orílẹ̀-èdè gbọ́dọ̀ ní fún ìmúdúró-ṣọ̀kan àti ìdàgbàsókè

àwùjọ bí Nàìjíríà bá fẹ́ dúró lórí ìgbé ayé *àjùmọ̀ni, àjùmọ̀ṣe, àjùmọ̀pín, àjùmọ̀rìn àti àjùmọ̀-fọkàntẹ̀* nínú *ìfimọ̀ṣọ̀kan* tó ní àfojúsùn ìṣèlú àti ètò ọrọ̀-ajé tó dúróore.

**Àgbálọgbábọ̀**

Láti ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún sẹ́yìn ni àwọn akéwì Yorùbá, yálà alohùn, onífọ́nrán tàbí àpilẹ̀kọ, ti dúró gẹ́gẹ́ bí *alóre*, tí wọ́n sì ń kó ipa takuntakun nípa títan ìmọ́lẹ̀ sí ohun tó bá rújú, pè àkíyèsí sí oríṣiríṣi ohun tó yẹ láti gbé yẹ̀wò, tàbí yíyòǹbó àwọn ohun àmúyẹ inú àṣà àti ìṣe àwùjọ lápapọ̀. Lóòótọ́, ìpèníjà bí: *ìwà ẹlẹ́yàmẹ̀yà, ìwà jẹgúdújẹrá, dákú-dájí-iná-ọba, sùnmọ̀mí gbígbé (Boko Haram)* àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ wà fún àwọn olóṣèlú. Síbẹ̀síbẹ̀, àpẹẹrẹ àti ìpèníjà ńlá ni àwọn olóṣèlú ọdún 1960 sí ọdun 1966 tí wọ́n di ipò ìṣèlú mú ní ẹkùn ìjọba Àríwá (Northern Region), Ìwọ̀ Oòrùn (Western Region) àti Ìlà Oòrùn (Eastern Region) pẹ̀lú ìmọ̀ abínibí agbègbè ẹnìkọ̀ọ̀kan wọn jẹ́ fún àríkọ́gbọ́n.

Àwọn akéwì àpilẹ̀kọ Yorùbá bojú wẹ̀yìn lórí ibi tí ètò ìṣèlú Nàìjíríà ti bẹ̀rẹ̀, ibi tó dé dúró àti ohun tó ṣeé ṣe kó gbẹ̀yìn ọ̀rọ̀ bí ìfọwọ́sowọ́pọ̀ fún àtúnṣe kò bá sí ní kánmọ́kánmọ́. Láìsí tàbí ṣùgbọ́n, a fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ìmọ̀ abínibí jẹ́ àpẹẹrẹ àwòkọ́ṣe rere tó lè ran Nàìjíríà lọ́wọ́ nínú ètò ìṣèlú àti ọrọ̀-ajé. Àwọn akéwì, nínú àwíjàre wọn, tẹnu mọ́ ọn pé ìmọ̀ abínibí kì í ṣe ohun àforírò lásán, ṣùgbọ́n ohun tó wà, tí ó sì jẹ́ *a-jẹ́-bí-idán* ìlànà tó dájú láti ayébáyé fún ìlò àwùjọ tó mọ rírì rẹ̀. Wọ́n tún ṣe àwíjàre lórí pàtàkì ṣíṣe àmúlò ìmọ̀ abínibí fún ètò ìṣèlú Nàìjíríà, pàápàá lórí bó ṣe nira láti sọ pàtó èbúté ibi tí ọkọ̀ orílẹ̀-èdè yìí yóò gúnlẹ̀ sí.

Àkíyèsí wà pé lílo ìmọ̀ abínibí gẹ́gẹ́ bó ṣe jẹyọ nínú àwọn àṣà ìbílẹ̀ ẹ̀yà kọ̀ọ̀kan tó parapọ̀ di Nàìjíríà yóò polongo Nàìjíríà gẹ́gẹ́ bí orílẹ̀-èdè tó ní ìlànà àti àṣà ajẹmọ́-ìṣèlú. Nípa báyìí, àtúnṣe tó jọjú fún ìmúdúró lè wáyé lórí èròǹgbà ajẹmọ́-ìṣèlú alákòóyawọ́ tó lè ran ìbára-ẹni-gbépọ̀ lọ́wọ́. Bákan náà, yóò tún jẹ́ ìwúrí fún àwọn ọmọ orílẹ̀-èdè yìí pé ìmọ̀ abínibí wọn kò ní parun nítorí ọ̀làjú tó gbòde kan. Ọ̀nà kan gbòógì nìyí fún àdáríjọpọ̀ ẹ̀yà tó para pọ̀ di Nàìjíríà láti ṣàfihàn àṣà àjogúnbá wọn bí àwùjọ tó ní òmìnira ìrònú láìrọ̀gbọ̀kú lé àṣà ìṣèlú àtòkèèrè-wá nìkan. Ọ̀kan lára ọ̀nà àtúnṣe ìmúbọ̀sípò ni ìdìbò ọdún 2015 tó wáyé wọ́ọ́rọ́wọ́ tí kò sì pín Nàìjíríà yẹ́lẹyẹ̀lẹ gẹ́gẹ́ bí orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà ti wòye pẹ̀lú *àsọtẹ́lẹ̀* ní nǹkan bí ọdún mẹ́rin sẹ́yìn. Ǹjẹ́ a wá lè sọ ya-n-ya pé ètò ìṣèlú Nàìjíríà ti ń rẹ́sẹ̀ walẹ̀, ó sì ti ń dúróore bí?

## Ìwé Ìtọ́kasí


Abímbọ́lá, W. (2006). *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá.* Ìbàdàn: University Press Plc.

-------- (2006). *Àwọn Ojú Odù Mẹ́rẹ̀ẹ̀rìndínlógún.* Ìbàdàn: University Press Plc.

Adébọ̀wálé, O. (2014). "Lítíréṣọ̀Yorùbá, ọ̀rọ̀ Ààbò àti Ìdàgbàsókè Orílẹ̀-Èdè" nínú *Yorùbá: Journal of the Yoruba Studies Association of Nigeria.* Vol.7, No.3. pp 1-31.

Adégbindin, O. (2012). "*Yorùbá Idea of the Good Life* in *Ifá Literary Corpus: A critical Analy*sis" nínú *Ìbàdàn Journal of Humanistic Studies*. No. 22 & 23. pp 165-183.

Adéoyè, C.L. (2005). *Àṣà àti Ìṣe Yorùbá*. Ìbàdàn: University Press Plc.

Adéwọlé, L. (1987). *Àlàyé Akéwí*. Ìbàdàn: Oníbọnòjé Press & Book Industires (Nig.) Ltd**.**

Adélékè, D. (2010). "Nàìjíríà Dòrí", nínú Ọ̀pádọ̀tun, T. (Olótùú) *Àwọn Akéwì Ṣàṣàrò*. Ìbàdàn: University Press Plc.

Adétúnjí, A. (1989). *Fọ̀rànrorawò àti Àwọn Ewì Mìíràn*. Ìbàdàn: Oníbọnòjé Press & Book Industries (Nig.) Ltd**.**

Adéyẹmí, L..(2005). "Ìhà tí Òǹkọ̀wé Ìwé Ìtàn-Àròsọ kọ sí Ọ̀rọ̀ Ìṣọkan Orílẹ̀-Èdè Nàìjíríría". nínú *Láàǹgbàsà*. No.11, pp 139-154.

----------- (2006). *Tíọ́rì Lítíréṣọ̀ ní Èdè Yorùbá.* Ìjẹ̀bú-Òde: Shebíotimọ Publications.

Akínjógbìn, I.A & Àyándélé, E.A (1980). 'Yorùbá up to1800" in *Groundwork of Nigerian History*. Ikime. O. (ed.). Ìbàdàn: Heinemann Educational Books (Nigeria) Limited. pp 121-143.

Akíntúndé, J.O. (1967). "The Demise of Democracy in the First Republic of Nigeria: A Casual Analysis". In *Odù: University of Ifẹ̀ Journal of African Studies.* Vol.4, No. 1, pp 3-28.

(2001) *A Dictionary of the Yorùbá Language.* Ìbàdàn: University Press Plc.

Àlàbá, O. (2011). "Ìhà tí àwọn Ọmọ Nàìjíríà kọ sí Èdè Ilẹ̀ wọn: Yorùbá gẹ́gẹ́ bí Àpẹẹrẹ" nínú *Láàǹgbàsà*. No 15, pp 46-57.

Àtàrí Àjànàkú (àlàjẹ́, 2011). *Orin Ewúro*. Ìbàdàn: Ìbàdàn Cultural Studies Group.

Awóbùlúyì, O. (1990). (ed.) *Yorùbá Metalanguage (Èdè-Ìperí Yorùbá)* Vol. II. Ìbàdàn: University Press Plc.

Bamgbose, A. (2004). (ed.) *Yorùbá Metalanguage (Èdè-Ìperí Yorùbá).* Vol. I. Ìbàdàn: University Press Plc.

Bámiṣhaiyé, A. (1976). "Ethnic Politics as an Instrument of Unequal Socio-Economic Development In Nigeria's First Republic" in *Ethnic Relations in Nigeria*. Sanda, A. O. (ed.). Ìbàdàn:The Caxton Press (West Africa) Limited. pp 71-91.

Baradat, L.P (2006). *Political Ideologies: Their Origins and Impact*. Ninth Edition. New Jersey: Pearson Education Inc.

Bestman, M (1991). "Literature and Development: the African Situation", *In honour of Professor Ayọ̀ Bámgbóṣé.* Ṣóyoyè, F, A. & Adewole, L.O (eds.), Ifẹ̀; African Language &Literature Series. No.3 pp 56-64.

Bọ́lájí, S. L (1981). *Yorùbá Living Heritage*. Ìbàdàn : Ọmọlẹ̀yẹ Publishing Company.

Brannigan, J.(1999). "Introduction: History, Power, and Politics in the Literary Artifact", In *Literary Theories: A Reader and Guide*. Wolfreys S. J. (ed.) New York: New York University Press pp. 417-427.

Dáramọ́lá, O. & Jéjé, A. (1975). *Àwọn Àṣà àti Òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá.* Ìbàdàn: Oníbọnòjé Press & Book Industries (Nig) Ltd.

Douglas, J.O.(2012). "Traditional Igbo Morality and the Challenge of Good Leadership in Contemporary Nigeria:

A Philosophical Reflection" in *Ihafa: A Journal of African Studies.* Vol .5, No.4, pp23-46.

Dúrówadé, O. & Táíwò, O. (1998). "Culture and Society in Africa'', in *The Essentials of African studies*, Vol 2. Revised Second Edition, Olúwọlé, S.B. & Fáluyì. K, (eds.). Lagos: General African Studies Programme. pp 41-76.

Ẹlẹ́buìbọn, Y. (1999). *Ìrìnàjò Ẹ̀dá.* Ìbàdàn : Caltop Publications (Nigeria) Limited.

Fálétí, A. (2009). "Ọmọlúàbí: The Golden Attribute of a Yorùbáman" in *Ọmọlúàbí; Its Concept and Education in Yorùbáland,* Ògúndèjì, A. & Àkàngbé, A. (eds.) Ìbàdàn: Ìbàdàn Cultural Studies Group. pp 113-128.

Ifidon, E.A.(2003) "Ethnicity, Differential and the Problem of Nation-Building" in *The Amalgamation and its Enemies (An Interpretive History of Modern Nigeria)*. Ọláníyan, R.A (ed.) Ilé-Ifẹ̀: Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University Press Limited. pp 167-182.

Ilésanmí, T.M. (1991). "Yorùbá Oral and Written Literature: Towards a Cultural Formulation for a Critical Analysis". in *In honour of Professor Ayọ̀ Bámgbóṣé.* Ṣóyoyè, F.A. & Adewole, L.O (eds.) Ifẹ̀ African Language & Literature Series. No.3 pp 65-77.

Ìṣọ̀lá, A. (1991). "Image of the Ọba in Yorùbá Novel" in *In honour of Professor Ayọ̀ Bámgbóṣé.* Ṣóyoyè, F, A. & Adewole, L.O (eds.) Ifẹ̀ African Language & Literature Series. No.3 pp 78-84.

------ (2010). *Making Culture Memorable: Essays on Language, Culture and Development*. Ọládípọ̀,O. & Adélékè, D. (eds.). Ìbàdàn: Hope Publications Ltd.

------ (2012). *Òrìṣà wo Ló ń Gun Òǹkọ̀wé?* Ìbàdàn: DB Martoy Books.

Kọláwọlé, D. (1988) "Political Violence - A Case Study of Ondo State" In *Nigeria's Second Republic*. Ayẹni, V. & Ṣórẹ̀mẹ́kún, K. (eds.) Lagos: Daily Times Publications. pp.135-144.

Ògúndèjì, P.A (2013). "Ipò Ọba Lánàá, Lónìí àti Lọla", Pépà àpilẹ̀kọ tí Ọ̀jọ̀gbọ́n Ògúndèjì, P.A kà níbi ayẹyẹ àjọ̀dún ọdún kẹwàá ìgoróyè fún Ọba Wahaab Oyèdọ̀tun Ọ̀ràngún ti Ìla-Ọ̀ràngún pp 1-18.

Ògúnṣínà, B. (1988). "Òǹkọ̀wé Yorùbá àti Ìdàgbàsóké Orílẹ̀-Èdè Nàìjíríà," nínú *Ifẹ̀: Annals of the Institute of Cultural Studies*. Ile-Ife. No. 2. Àjùwọ̀n, B. (ed.) pp 84-93.

----------- (2013) "Ojúwòye Yorùbá Lórí Ọ̀rọ̀ Ààbò àti Ìfaradà Ẹ̀sìn nínú Ìdàgbàsókè Orílẹ̀-Èdè". nínú *Yorùbá*: *Jọ̀nà Ẹgbẹ́ Onímọ̀-Èdè Yorùbá*. Vol 7 No. 2: 1-24.

Òkédòkun, A. (2003). "Nígbà Tàwa" nínú *Kíké Olóbùró*. Òní, K. (Olótùú). Òṣogbo: Sumob Publishers. pp 26-33.

Olúmúyìwá. T.O (2014). "Indegenous Knowledge in Yorùbá Video Films: A Case Study of *Àbẹ̀ní Alágbo-Òru*" A Paper Presented at the National Conference of Ẹgbẹ́ Onímọ̀-Èdè Yorùbá (Yorùbá Studies Association of Nigeria), University of Ìlọrin, Ìlọrin, Kwara State, October 13-17, 2014. pp 1-16.

Ọládàpọ̀, O. (1973). *Àròyé Akéwì (Apá Kínní).* Ìbàdàn: Oníbọnòjé Press & Book Industries (Nig.) Ltd.

Ọládípọ̀, O. (2007). “The Substance and Significance of Yorùbá Philosophy”, In *Yorùbá: Journal of the Yoruba Studies Association of Nigeria.* Vol.4, No.1. pp 1-13.

Ọláníyan, R.A & Àlàó, A. (2003). “The Amalgamation, Colonial Politics and Nationalism” in *The Amalgamation and its Enemies (An Interpretive History of Modern Nigeria)*. Ọláníyan, R.A (ed.) Ilé-Ifẹ̀: Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University Press Limited. pp 1-22.

Ọ̀pádọ̀tun, O. (1976). *Àròfọ̀ Ọ̀pádọ̀tun.* Ìkẹjà: Longman Nigeria Limited.

Ọ̀wóadé, M.A. (1988) “Law and Order” In *Nigeria’s Second Republic*. Ayẹni, V. & Ṣórẹ̀mẹ́kún, K. (eds.) Lagos: Daily Times Publications. pp 145-159.

Owólabí, K. (2001). “Wisdom is Mightier than Might: Fagunwa’s Narrative and the Yorùbá Communal Philosophy” In *Mass Culture in Africa: Journal of Cultural Studies* Vol. 3, No. 2. pp 566-573.

Payne, R.J & Nassar, J.R (2006). *Politics & Culture in the Developing World: The Impact of Globalization*. Second Edition. New York: Peaerson Education Inc.

(1991) *Quadrilingual Dictionary of Legislative Terms (English, Hausa, Igbo, Yorùbá)* Lagos: Nigerian Educational Research and Development Council (NERDC).

Rajasekaran, B. (1992). “A Framework for Incorporating Indegeneous knowledge System into Agricultural

Research and Extension Organisation for Sustainable Agricultural Development in India" Doctoral Dissertation, Iowa: Iowa State University.

Rodney, W. (2009). *How Europe Underdeveloped Africa*. Abuja; Panaf Publishing Inc.

Ṣàngótóyè, O. (2010). "Ètùtù ìṣọ̀kan" nínú Ọ̀pádọ̀tun, T. (Olótùú) *Àwọn Akéwì Ṣàṣàrò*. Ìbàdàn: University Press Plc.

Srivastava, A.R.N (2013). *Essentials of Cultural Anthropology*. Second Edition. New Delhi: PHI Learning Private Limited.

Steiner, A. (2008). "Indigeneous Knowledge in Disaster Management in Africa" Pretoria, South Africa, Retrieved from http://www.icsu.org/africa/newscentre/news/Appendix9 indegeneous Booklet unep.pdf

Tyson, A. (1999). *Critical Theory Today: A User-Friendly Guide*. New York: Garland Publishing Inc.